# ÌLÒ Ẹ̀FẸ̀ FÚN YÍYANJÚ ÌṢÒRO ÌBÁRA-ẸNI-GBÉ-PỌ̀ AJẸMÓṢÈLÚ GẸ́GẸ́ BÍ Ó ṢE HÀN NÍNÚ ÀWỌN ÀṢÀYÀN ÌWÉ ERÉ-ONÍTÀN YORÙBÁ

**[1] Adágbádá, O. O. ati [2]Adéfowópè, G.O.**
olufadekemiadagbada@gmail.com
Corresponding author-kemiadefowope@gmail.com 08132587998
**[1]Department of Linguistics and Nigerian Languages**
**Olabisi Onabanjo University, Ago-Iwoye**

**[2]Our Lady of Apostles Secondary School (Private), Ijebu-Ode**

**Àṣamọ̀**
*Ipò tí àwùjọ wà nípa ètò òṣèlú bó-o-ba-o-pá, bó-ò-ba-o-bù-ú-lẹ́sẹ̀, ìrẹ́nijẹ, ìṣowó ìlú mọ́kumọ̀ku, jàgídíjàgan àti àwọn ìwà ìbàjẹ́ mìíràn tí ó gbilẹ̀ lágbo òṣèlú ni ó bí iṣẹ́ ìwádìí yìí. Èròǹgbà iṣẹ́ ìwádìí yìí ni láti wò bí ìlò ẹ̀fẹ̀ ṣe lè yanjú ìṣòro ìbára-ẹni-gbé-pọ̀ nínú ètò ìṣèlú, nípa fífi òótọ́ ọ̀rọ̀ gún aṣebi lára, kí èyí lè jẹ́ àríkọ́gbọ́n fún àwọn ẹlòmíràn, tí yóò sì tún kọ́ àwùjọ ní ẹ̀kọ́ ìwà ì-kóra-ẹni-níjàánu àti ìwà ọmọlúàbí. Ọgbọ́n ìṣèwádìí tí iṣẹ́ ìwádìí yìí tọ̀ ni ṣíṣe ìtúpalẹ̀ kíkún lórí àkóónú àwọn ìwé méjì tí a ṣà yàn fún ìtúpalẹ̀ lórí bí àwọn òǹkọ̀wé ṣe lo ẹ̀fẹ̀, láti yanjú àwọn ìṣòro ìbára ẹni-gbé-pọ̀ ajẹmóṣèlú. Àwọn ìwé eré-onítàn ajẹmẹ́fẹ̀ ní èdè Yorùbá tí a yàn ni Orí Mẹ̀kúnnù àti Àgbò Orí-Ìso. Tíọ́rì ìfojú-ìmọ̀-ìbára-ẹni-gbé-pọ̀-àwùjọ-wò-lítíréṣọ̀ (Sociology of Literature) àti tíọ́rì ìmọ̀ Ìlò-Àmì Ajẹmáwùjọ (Social-Semiotic) ni ọ̀pákùtẹ̀lẹ̀ tí iṣẹ́ ìwádìí yìí rọ̀ mọ́, láti wo bí ìlò ẹ̀fẹ̀ ṣe lè dẹ́kun àwọn ìwà ìbàjẹ́ ní agbo òṣèlú, nìwọn ìgbà tí ó jẹ́ pé àwùjọ ni àwọn olóṣèlú ń ṣe ìjọba lé lórí àti pé inú àwùjọ ni lítíréṣọ̀ ti hù jáde. Iṣẹ́ ìwádìí yìí ṣe àwárí pé ìlò ẹ̀fẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ọ̀nà ìfòótọ́-ọ̀rọ̀-gúnni-lára, lè kọ́ àwọn olóṣèlú àti àwọn tí ó wà nídìí ètò ìṣàkóso ní ẹ̀kọ́ ìwà ì-kóra-ẹni níjàánu, tí ìfọ̀kànbalẹ̀ àti àlàáfíà yóò sì jọbá ní àwùjọ, gẹ́gẹ́ bí ó ṣe jẹ yọ nínú àwọn àṣàyàn ìwé àmúlò. Ìgúnlẹ̀ iṣẹ́ ìwádìí yìí ni pé kí ìjọba àti àwùjọ má fi ojú rénà àwọn àṣà ilẹ̀ wa pátápátá, kí a fi àyè gba ìlò ẹ̀fẹ̀ gẹ́gẹ́ bíi ijánu fún ìwà ìbàjẹ́, kí ẹ̀mí ìkóra-ẹni-níjàánu lè fẹsẹ̀ múlẹ̀ síi ní àwùjọ, pàápàá ní agbo òṣèlú. Yàtọ̀ sí èyí, kí ètò ààbò àti ti ìdájọ́ má dijú sí ẹjọ́ títa-lólobó ìwà ìbàjẹ́ nínú ẹ̀fẹ̀ tí wọ́n bá fi àwọn aṣèbàjẹ́ lágbo òṣèlú ṣe, kí wọ́n lè yí ìwà padà. Bákan náà, kí àwọn olóṣèlú tí pẹ̀tẹ̀pẹ́tẹ̀ ẹ̀fẹ̀ bá ta sí lára gbìyànjú láti ṣe àtúnṣe.*

**Kókó-ọ̀rọ̀:** Ẹ̀fẹ̀, Ìbára-ẹni-gbé-pọ̀, Ìkóra-ẹni-níjàánu, Ìṣòro, Ìṣèlú

## Ìfáárà

Fífi ẹ̀fẹ̀ yanjú ìṣòro ìbára-ẹni-gbé-pọ̀ nínú ètò ìṣèlú ni iṣẹ́ yìí dá lé. Ní ṣíṣe èyí, a ṣe àgbéyẹ̀wò bí ìlò ẹ̀fẹ̀ ṣe yanjú ìṣòro ìbára-ẹni-gbé-pọ̀ tí ó jẹ mọ́ ìṣèlú gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hàn nínú àwọn àṣàyàn ìwé eré-onítàn Yorùbá. Lárá àwọn ìṣòro wọ̀nyí ni ìpàniyàn, ìṣowó ìlú mọ́kumọ̀ku, ìrẹ́nijẹ, rìbá gbígbà àti fífúnni, ìwà jàgídí-jàgan, ìpáǹle, iró pípa, ọ̀tẹ̀ dídì, níná owó ní ìná àpà, ọgbọ́n ẹ̀tàn, ojúkòkòrò, ìjà jíjà àti àwọn ìpèníjà mìíràn tí ó ń dí àlàáfíà àwùjọ lọ́wọ́. ìdí tí a rò pé èyí fi rí bẹ́ẹ̀ ni ẹ̀kọ́ ìwà ọmọlúàbí àti ìwà ìkóra-ẹni-ní-ìjánu tí kò fi ẹsẹ̀ rinlẹ̀ mọ́ bíi ti ayé àtijọ́. Kì í ṣe pé àwọn ìpèníjà wọ̀nyí kò sí nínú ètò ìṣèjọba ìgbà ìwáṣẹ̀, àmọ́ àwùjọ máa ń pe àkíyèsí àwọn oníwà kò-tọ́ sí ìwà ìbàjẹ́ ọwọ́ wọ́n, nípa fifi wọ́n ṣẹ̀fẹ̀, tí wọn yóò sì fi wọ́n rẹ́rìn-ín ẹlẹ́yà. Èyí máa ń wáyé láìní ọwọ́ líle tàbí ọwọ́ òfin à ń kó ara ẹni lọ sí ilé-ẹjọ́ nínú. Ẹ̀fẹ̀ tí àwùjọ ìgbà àtijọ́ máa ń fi àwọn oníwà ìbàjẹ̀ ní agbo òṣèlú ṣe máa ń wọ̀ wọ́n ní akínyẹmí ara. Èyí sì máa ń mú ìyípadà rere bá olùfaragbà, tí yóò sì jẹ́ ẹ̀kọ́ ìwà ìkóra-ẹni-ní-ìjánu fún àwọn tí ó kù, ju ilé-ẹjọ́ tí wọ́n ń gbé ara wọn lọ ní sáà bágbàmu yìí.

Èròngbà ẹ̀fẹ̀ ni láti fi òótọ́ ọ̀rọ̀ gún agbẹ̀fẹ̀ lára, nípa ìwà ìbàjẹ́ tí ó ń hù tàbí tí ó ti hù, tí ó sì máa ń jẹ́ àríkọ́gbọ́n fún ẹlòmíràn láti yàgò fún irú ìwà kò-tọ́ bẹ́ẹ̀ (Deterrent to others). Ènìyàn kò le è fi ara rẹ̀ ṣẹ̀fẹ̀, ẹlòmíràn ni ó máa ń fini ṣẹ̀fẹ̀. Aṣẹ̀fẹ̀ lè má dárúkọ agbẹ̀fẹ̀ ní sàn-án, àmọ́ agbẹ̀fẹ̀ fúnra rẹ̀ yóò mọ̀ pé òun ni àṣẹ̀fẹ̀ ń bá wí, ó ṣe é ṣe kí àwùjọ́ mọ agbẹ̀fẹ̀, wọ́n sì lè má mọ̀ ọ́n. Ẹ̀fẹ̀ kì í mú ẹ̀rín wá fún agbẹ̀fẹ̀, bí ó bá sì rẹ́rìn-ín, ẹ̀rín ìyàngì ni. Ẹ̀fẹ̀ máa ń fa ìtìjú àti àbùkù bá agbẹ̀fẹ̀, tí èyí lè mú kí ó yí ìwà rẹ̀ padà, nípa ṣíṣe àtúnṣe tí ó tọ́. Bákan náà, ìtìjú àti ẹ̀sín tí ẹ̀fẹ̀ bá mú bá ènìyàn lè mú kí irú ẹni bẹ́ẹ̀ fi òru bojú sá lọ nílùú tàbí kí ó gbẹ̀mí ara rẹ̀, bí agbára rẹ̀ kò bá le è gbé oró ọfà tí ẹ̀fẹ̀ dá sí i lára, tí yóò sì já sí pé kàkà kí ilẹ̀ ó kú, ilẹ̀ yóò ṣá ni fún irú ẹni bẹ́ẹ̀. Àkíyèsí mìíràn tí a tún ṣe ni pé aṣẹ̀fẹ̀ dúró gẹ́gẹ́ bí alóre àti ọlọ́pàá (pàápàá ní àwùjọ Yorùbá), tí ó máa ń ṣòfintótó ọ̀rọ̀ tó ń lọ ní àwùjọ, tí ó máa ń fi òótọ́ ọ̀rọ̀ gún aṣebi lára, tí ó sì máa ń fi àwọn òmùgọ̀ àti ẹni tó bá ń hùwà kò-tọ́ rẹ́rìn-ín ẹlẹ́yà. Aṣẹ̀fẹ̀ kò gbọdọ̀ méfòó. Iṣẹ́ aṣẹ̀fẹ̀ ni láti fimú fínlẹ̀ wá fìn-ín-ìdí-kókò nípa ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ, ní èròngbà àtigún aṣebi ní kẹ́ṣẹ́ nípa títú àṣírí amòòkùn-ṣìkà tàbí aṣèbàjẹ́, èyí tí ó lè fa ọgbẹ́ ọkàn àti egbò àdáàjiná sí oókan àyà aṣebi.

## Tíọ́rì Àmúlò

### Tíọ́rì Ìfojú-Ìmọ̀-Ìbára-Ẹni-Gbé-Pọ̀-Áwùjọ-Wo Lítíréṣọ̀ (Sociology of Literature)

Ọ̀pẹ́fèyítìmí (2014) ṣe àlàyé ohun tí ìlànà lámèyítọ́ èyí jẹ mọ́. Ìgbàgbọ́ àwọn onímọ̀ ni pé èso àwùjọ ni lítíréṣọ̀ jẹ́. Ohun tí a pè ní "Soṣiọ́lọ́jì Lítíréṣọ̀" jẹ́ ọ̀rọ̀ tí onímọ̀ èrò ìjìnlẹ̀ kan tí a ń pè ni Hippolyte Taine; ọmọ ilẹ̀ Faransé rọ fúnra rẹ̀ láàrin ọdún 1828 sí 1893. Ète láti sọ àgbéyẹ̀wò iṣẹ́ ọnà dàbí ti ìmọ̀ sáyẹ́nsì ló fa ìṣẹ̀dá Soṣíọ́lọ́jì lítíréṣọ̀, tí ó sì jẹ́ ìmọ̀ tuntun ní agboolé ẹ̀kọ́ nípa iṣẹ́ ọnà. Tíọ́rì Soṣiọ́lọ́jì Lítíréṣọ̀ jẹ́ abala ìmọ̀ méjì tí ó papọ̀, Soṣiọ́lọ́jì àti Lítíréṣọ̀. Tí a bá fẹ́ wádìí ìjìnlẹ̀ nípa àwùjọ àti ẹ̀dá inú rẹ̀, Soṣiọ́lọ́jì àti Lítíréṣọ̀ ni a lè pè láti wá yanjú irú ìṣòro tí a bá dojúkọ. Ìdí nìyí tí Hoggart nínú Adéyẹmí (2006) fi jẹ́rìí sí i pé, "Without the full literary witness, the student of society will be blind to the fullness of a society" (Láìsí ẹ̀rí kíkún láti ipasẹ̀ iṣẹ́ lítíréṣọ̀, akẹ́kọ̀ọ́ nípa àwùjọ kò lè rí ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ). Ohun ti èyí túmọ̀ sí ni pé ìmọ̀ lítíréṣọ̀ àwùjọ kan ṣe pàtàkì bí a bá fẹ́ ní ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ nípa irú àwùjọ bẹ́ẹ̀. Pẹ̀lú àkíyèsí yìí, a lè sọ pé Soṣiọ́lọ́jì Lítíréṣọ̀ ni ẹ̀kọ́ ìmọ̀ nípa ìbáṣepọ̀ tó wà láàrin lítíréṣọ̀ àti àwùjọ. Ohun tí àwọn onímọ̀ ń sọ ni pé lítíréṣọ̀ kò wà lásán, a kò sì lè ya lítíréṣọ̀ àti àwùjọ ti ó bí i. Òǹkọ̀wé gan-an fúnra rẹ̀ kò já bọ́ láti ọ̀run, inú àwùjọ ló ti wá, gbogbo ohun tí ó bá ń ṣẹlẹ̀ sí àwùjọ, òun náà nípìn-ín níbẹ̀. Gbogbo ìrírí àwùjọ kò sẹ́yìn rẹ̀, pàápàá èyí tó jẹ mọ́ ètò ìbára-ẹni-gbé-pọ̀; ètò ìṣẹ̀lú, ọrọ̀-ajé, ẹ̀sìn, ètò ààbò àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Síwájú síi, inú àwùjọ ni òǹkọ̀wé ti ní ìmọ̀ tí ó gbá jọ, ìrírí rẹ̀, ìrònú rẹ̀ àti ibi ti ìmọ̀ rẹ̀ fẹ̀ dé. Nítorí náà, Soṣiọ́lọ́jì Lítíréṣọ̀ ni ìbáṣepọ̀ tó wà láàrin òǹkọ̀wé, àwùjọ àti iṣẹ́ ọnà aláwòmọ́ lítíréṣọ̀ gẹ́gẹ́ bí ààrò mẹ́ta ti kì í da ọbẹ̀ nù. Bí eegun ṣe wọ inú ẹran, ti ẹran sì wọ inú eegun, ni ọ̀rọ̀ òǹkọ̀wé, àwùjọ àti lítíréṣọ̀ jẹ́. Ẹ̀rí tí ó dájú ni pé gbogbo iṣẹ́ ọnà aláwòmọ́ lítíréṣọ̀ ló ní àjọṣepọ̀ pẹ̀lú àwùjọ tí a kọ wọ́n fún, yálà eré-onítàn, ìtàn-àròsọ tàbí ewì.

### Tíọ́rì Ìmọ̀ Ìlò-Àmì Ajẹmáwùjọ (Socio-Semiotics)

Tíọ́rì mìíràn tí a lò láti fi ṣe àtúpalẹ̀ iṣẹ́ ìwádìí yìí ni tíọ́rì Ìmọ̀ Ìlò-Àmì Ajẹmáwùjọ, èyí tí ó jẹ́ ẹ̀ka lábẹ́ tíọ́rì ìmọ̀ ìlò-Àmì. Tíọ́rì ìmọ̀ ìlò-Àmì Ajẹmáwùjọ jẹ́ ẹ̀kó nípa ìhà ìtumọ̀ ajẹmáwùjọ àti ti agbára ìgbésẹ̀ ìfúnnítumọ̀ ènìyàn nínú yíya àwòrán olúkúlukù àti àwùjọ. Tíọ́rì yìí ni ó máa ń wádìí ìṣe ẹ̀dá tó lápẹẹrẹ, nínú àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ ajẹmáwùjọ àti ajẹmáṣà, tí ó sì tún máa ń gbìyànjú láti ṣàlàyé ìfúnnítumọ̀ gẹ́gẹ́ bí ìṣe àwùjọ. Onímọ̀ tíọ́rì ìmọ̀ Ẹ̀dá-èdè kan tí orúkọ rẹ̀ ń jẹ́ Michael Halliday ló kọ́kọ́ ṣàfihàn ọ̀rọ̀ ìperí ìmọ̀ ìlò-àmí ajẹmáwùjọ sínú ìmọ̀ ẹ̀dá-èdè ní ọdún 1978. Lára àwọn agbátẹ̀rù tíọ́rì yìí ni a ti rí Ajíbádé (2003), Àránsí (2010), Pierce, Lotman, Frye àti Egorov nínú Ọ̀pẹ́fèyítìmí (2014), Lauretics nínú Fáṣeun (2017) àti Adéọ̀ṣun (2017).

Àwọn onímọ̀ wọ̀nyí gbà pé ìmọ̀ àwùjọ-àdáyébá, ìbára-ẹni-gbé-pọ̀, ẹ̀dá-èdè àti ìmọ̀ ìlò-àmì jẹ mọ́ ẹ̀kọ́ nípa àmì bíi ọ̀rọ̀, ìró, ìfarasọ̀rọ̀, tìlùtifọn, àwòrán, àwọn àmì mìíràn fún ìbára-ẹni-sọ̀rọ̀, ìbẹ́ranko-sọ̀rọ̀, èyí tí ẹ́ranko ń lò fi bá ara wọn sọ̀rọ̀ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Èyí túmọ̀ sí pé onírúurú ìró-èdè jẹ́ àmì tí ó ní àgbọ́yé láàrin àwùjọ tí a ti ń lò ó, àti pé, bí àmì kò bá ní ìtumọ̀ sí òṣùnṣùn afọ̀, ohun kan ṣáá lásán ni ó jẹ́. Àwọn onímọ̀ tíọ̀rì ìlò-àmì ajẹmáwùjọ gbà pé ìlò-èdè jẹ́ abáyéyí. Èyí ni ohun tí ó ń yípadà tàbí tí kò dúró sí ojú kan rárá, tó sì ń pè fún àjọṣepọ̀ tí ó lóòrìn láàrin olùbánisọ̀rọ̀ àti olùgbọ́. Wọ́n tún gbà wí pé àmì ni ènìyàn fi ń sọ̀rọ̀, òun ló sì ń ṣàkóso ìdarí ẹ̀dá. Wọ́n fi òté lé e pé èdè ni ó jẹ́ ìpìlẹ̀ fún àṣà, tí lítíréṣọ̀ onírúurú sì hù láti inú àṣà. Kò sí àríyànjiyàn nínú èrò pé kò-ṣe-é-má-níí ni ọ̀rọ̀ àmì gẹ́gẹ́ bí ìlànà ibára-ẹni-sọ̀rọ̀ àti ìdára-ẹni-lẹ́kọ̀ọ́ ni àwùjọ ẹ̀dá. Ọ̀pẹ́fèyítìmí (2014) gbà pé ìró-èdè jẹ́ àmì ìtumọ̀ tí ó ti di ìtẹ́wọ́gbà ni àwùjọ kan, ó sì jẹ́ òpómúléró fún ìbánisọ̀rọ̀ àti ìbágbépọ̀ ẹ̀dá. Níwọ̀n ìgbà tí ó jẹ́ pé ènìyàn lè gbé èrò ọkàn rẹ̀ jáde nípa lílo àmì, tí yóò sì ní ìtumọ̀ kíkún sí òṣùnṣùn afọ̀, ìdí nìyí tí iṣẹ́ yìí fi lo tíọ̀rì yìí gẹ́gẹ́ bí òdiwọ̀n fún ìlò àmì láti fini ṣẹ̀fẹ̀, tí yóò sì jẹ́ iṣẹ́ tí a rán an fún olùfaragbà-ẹ̀fẹ̀.

## Oríkì Ẹ̀fẹ̀

Díẹ̀ lára àwọn onímọ̀ tó ti ṣiṣẹ́ takuntakun lórí ohun tí ẹ̀fẹ̀ jẹ́ ni 'Ebewo (1988), Hornby (2000), Adéjùmọ̀ (2001), Iwu (2009) Raj (2012), Adékúnlé (2014), Ogonna (2016), Alugbin (2020), àti Moody nínú Obuh (2022). Àwọn onímọ̀ wọ̀nyí fún ẹ̀fẹ̀ ní oríkì látàrí ojú ìwòye tí wọ́n fi wò ó. Moody nínú Obuh (2022) tọ́ka sí ẹ̀fẹ̀ gẹ́gẹ́ bí iṣẹ́ ọnà tí ó máa ń tàbùkù tàbí pẹ̀gàn àwọn ìwà kò-tọ́ tí ẹnìkan, ẹgbẹ́ kan tàbí olórí àti onípòjipò kan hù. Clark nínú Alugbin (2020) rí ẹ̀fẹ̀ gẹ́gẹ́ bí "Weapon of criticism that subject an object of discourse to critical analysis in order to expose the shortcomings of its expected standard". (Clark rí ẹ̀fẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ohun èlò ìṣòfintótó ìṣẹ̀lẹ̀ kan nípa olùfaragbà ní èròǹgbà àtiṣàfihàn ìwà ibi tí ó hù, èyí tí ó tako àgbékalẹ̀ ìwà àwùjọ). Horis nínú Adékúnlé (2017) ní ìwòye tirẹ̀ ni: "Satire does not seek to do harm or damage by its ridicule but seek to establish a shock of recognition and to make vice repulsive so that the vice will be expunged from the person or society under attack regardless of who is the immediate object of attack". (Ohun tí Adékúnlé ń sọ ni pé kì í ṣe pé ẹ̀fẹ̀ máa ń wá ìpalára fúnni tàbí kí ó ba nǹkan jẹ́ nípa fífiniṣẹ̀sín, ṣùgbọ́n ó máa ń ṣe àgbékalẹ̀ ìbẹ̀rù láti mú kí olùfaragbà ní ìmọ̀lára, tí èyí sì lè mú kí ìwà kò-tọ́ yìí kúrò lára olùfaragbà tàbí ẹni yòówù kí ó jẹ́). Bí a bá gún lé oríkì tí àwọn onímọ̀ fún ẹ̀fẹ̀, a ó ri pé dídẹ́kun tàbí mímú àdínkù bá ìwà ìbàjẹ́ ní àwùjọ ni ó jẹ́ ẹ̀fẹ̀ lógún, nípa fífi òótọ̀ ọ̀rọ̀ gún aṣebi lára, ní èròngbà pé kí agbèfẹ̀ ṣe àtúnṣe ìwà tí ó ń dí àlàáfíà àwùjọ lọ́wọ́. A wá lè sọ pé ẹ̀fẹ̀ jẹ́ àkójọpọ̀ ọ̀rọ̀ tí a gbé kalẹ̀ ní ọ̀nà ẹ̀rọ láti fi oníwà ìbàjẹ́ ṣẹ̀sín, kí ó lè jáwó nínú ìwà kò-tọ́ tí ó ń hù.

## Ìbára-ẹni-gbé-pọ̀ Ajẹmóṣèlú

Ètò ìṣèlú ilẹ̀ Nàìjíríà ni Fánílọlá àti Ọdẹ́bùnmi fi ṣẹ̀fẹ̀ nínú ìwé eré-onítàn tí wọ́n kọ. Ọ̀pọ̀ àwọn òǹkọ̀wé eré-onítàn gbà ara wọn gẹ́gẹ́ bí àwòjíiji àwùjọ, tí ó rínú róde bí àwùjọ ṣe rí, tí wọ́n sì máa ń gbé iṣẹ́ àtinúdá wọn lé ìrírí wọn ní ààrin àwùjọ. Ìbára-ẹni-gbé pọ̀ dá lórí àjọṣepọ̀ tí ó wà láàrin àwọn ẹ̀dá ènìyàn inú àwùjọ kan. Àwùjọ kọ̀ọ̀kan ni ó ní ìlànà àti òfin tí ó de ìbára-ẹni-gbé-pọ̀ rẹ̀. Bí àpẹẹrẹ, àwọn ìlànà tí ó rọ̀ mọ́ ètò ìṣèjọba nínú èyí tí ó jẹ mọ́ ètò ọrọ̀-ajé, ètò ààbò, ìṣèlú, ètò ìṣèdájọ́ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ ní àwọn òǹkọ̀wé àmúlò fi ṣẹ̀fẹ̀. Gẹ́gẹ́ bí a ti mọ̀, kò sí bí a ṣe lè rìn kí orí má mì. Níwọ̀n ìgbà tí àwọn ènìyàn tì ń ní ìbágbépọ̀ pẹ̀lú ara wọn, pàápàá nínú ètò ìṣèlú, ó di dandan kí àwùjọ ní ìrírí àwọn ìwà ìbàjẹ́ bí irọ́ pípa, èké ṣíṣe, òfófó, òlè, ìpànìyàn, ìmutí para, ìjà, ìmẹ́lẹ́, àkóbá ṣíṣe, ìwà ahun, ojo ṣíṣe, níná owó ní iná àpà, ìgbéraga, àìgbọràn, ìṣowó ìlú mọ́kumọ̀ku, ìrẹ́nijẹ, rìbá gbígbà àti fífúnni, ìwà jàgídí-jàgan, ìpáǹle, ọ̀tẹ̀ dídì, ọgbọ́n ẹ̀tàn, ojúkòkòrò àti àwọn ìwà kò-tọ́ mìíràn gẹ́gẹ́ bí ó ṣe jẹ yọ nínú àwọn ìwé àṣàyàn. Ìgbàgbọ́

àwọn òǹkọ̀wé àṣàyàn fún iṣẹ́ yìí ni pé àwọn olóṣèlú ilẹ̀ Náìjíríà máa ń lo ìpò wọn láti ni mẹ̀kúnnù lára, tí wọn sì tún máa ń jẹ gàba lé wọn lórí.

Ní àwùjọ Yorùbá, òfin àti ìlànà ìbára-ẹni-gbé-pọ̀ wà tí ó máa ń tọ́ mùtúmùwà sọ́nà nínú ìhùwàsí àti ìṣesí wọn. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé, kò sí àkọsílẹ̀ àwọn ohun ìjìnlẹ̀ wa ní ayé àtijọ́, tí ó sì jẹ́ pé inú ọpọlọ wọn ni àwọn òfin àti ìlànà wọ̀nyí wà, síbẹ̀, àwùjọ kì í fi bẹ́ẹ̀ fojú rénà àwọn òfin tí ó de ìbára-ẹni-gbé-pọ̀, pàápàá, nínú ètò ìṣèjọba, bẹ́ẹ̀ sì ni ẹ̀kọ́ ìwà ìkóra-ẹni-ní-ìjánu àti ìwà ọmọlúàbí fi ẹsẹ̀ rinlẹ̀, tí ó sì ń tọ́ ẹnikẹ́ni tí ó bá wà ní ipò ìṣàkóso sọ́nà. Àwùjọ Yorùbá kì í fi bẹ́ẹ̀ gbé ara wọn lọ sí ilé-ẹjọ́, nítorí ìgbàgbọ́ wọn ni pé a kì í ti kóòtù dé ṣọ̀rẹ́, àmọ́ wọ́n gbà pé ohun tí ó lè nani ju ẹgba lọ wà. Tí a bá wá rí ẹnikẹ́ni tí ó bá tàpá sí ìlànà yìí, irú ẹni bẹ́ẹ̀ yóò jẹ́ ìyan rẹ̀ nísu, nípa fífi irú ẹni bẹ́ẹ̀ ṣẹ̀fẹ̀, tí wọn yóò sì fi rẹ́rìn-ín ẹlẹ́yà. Iṣẹ́ yìí ṣe àyẹ̀wò bí ìwà ìbàjẹ́ ṣe fi ẹsẹ̀ walẹ̀ to lagbo òṣèlú ní sáà bágbàmu yìí, èyí tí ó tako àṣà, ìṣe àti ìhùwàsí àwùjọ, tí ó sì jẹ́ kí ó dàbí pé ilé ayé ṣòroo gbé fún àwọn ènìyàn, tí wọ́n ń ṣe ìjọba lé lórí, gẹ́gẹ́ bí ó ṣe jẹ yọ nínú àwọn ìwé àṣàyàn. Iṣẹ́ ìwádìí yìí ṣe àmúlò àwọn ìwé méjì; Orí Mẹ̀kúnnù (1991), tí Fánílọlá kọ àti Àgbò Orí-Ìso (2009), tí Ọdẹ́bùnmi kọ.

### Ìtàn Inú àwọn Ìwé Àmúlò ní Ṣókí

### Orí Mẹ̀kúnnù

Lẹ́yìn ikú ọba ìlú Tìkàlọ́jù, àwọn afọbajẹ péjọ láti yan ọba tuntun. Adékànmbí ń du ipò ọba, Òyékàn náà ń dù ú, nítorí pé ọmọ oyè ni àwọn méjèèjì. Adékànḿbí nìyìí, onígbèéraga ènìyàn ni. Jẹgúdújẹrá tí ń fi ojoojúmọ́ hùwà "Bámú-bámú ni mo yó, èmi ò mọ̀ pé ebi ń pa ọmọ ẹnìkan kan" ni pèlú. Òyékàn ní tirẹ̀ jẹ́ onírẹ̀lẹ̀, tí ó gùn lé orí ìwà "Bí a ṣe bi ẹrú náà ni a ṣe bí ọmọ", Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé Ifá lòdì sí yíyan Adékànmbí, tí àwọn ará ìlú náà sì tako yíyàn rẹ̀, àmọ́ àwọn afọbajẹ kọ ohùn sí Ifá lẹ́nu, wọn sì tún kọ etí ikún sí igbe mẹ̀kúnnù. Kòtò ikú tí wọn gbẹ́ sílẹ̀ de Òyékàn, orí àwọn mẹ̀kúnnù ló kó o yọ. Adékanmbí dórí oyè tán, ó fi ìyà pa àwọn mẹ̀kúnnù lórí. Adékanmbí lé ewúrẹ́ mẹ̀kúnnù kan ògiri, síbẹ̀síbẹ̀ kò padà. Nígbẹ̀yìn, orí àwọn mẹ̀kúnnù ja Ọba Adékànḿbí, àìsàn burúkú kọ lù ú, àwọn mẹ̀kúnnù tún dìde ogun sí i, tí ó sì jẹ́ pé ikú ni ó gbẹ̀yìn ọ̀rọ̀ rẹ̀.

### Àgbò Orí-Ìso

Àwàdà akọ tí Gbọ́lájókòó ṣe ló lé e kúrò ní abúlé eléwéerán, èyí ló sì mú kí baálẹ̀ àti ìlú pako dí ilé rẹ̀. Gbọ́lájókòó àti àwọn ẹbí rẹ̀ sá kúró ní Eléwéèran lọ sí ìlú Ibùdọ́-ọ̀tẹ̀. Ọ̀rẹ́ rẹ̀ Súlè ní ó gbà á sílé tayatọmọ, tí ìyẹn sì tún ràn án lọ́wọ́ láti bá a wá ibi tí yóò dako sí, kí ó lè máa rí oúnjẹ jẹ. Bí eré, bí àwàdà, pẹ̀lú iṣẹ́ àṣekára, Gbọ́lájókòó di olówó, tí ó sì ń fi owó ṣàánú. Ó fi owó tí ó ní mọ ẹbí àti mùtúmùwà, èyí ló mú kí àwọn aráàlú fi ẹ̀mí ìmoore hàn sí i nípa fífi àgbò ńlá kan ta á lọ́rẹ gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ ìfẹ́ tí wọ́n ní sí i. Àgbò yìí wọ ọba Kútańtì lójú, ó rán àwọn ẹ̀ṣọ́ rẹ̀ pé kí wọ́n lọ tú àgbò náà wá fún òun láti pa jẹ. Inú àwọn ará ìlú kò dùn sí ìwà ojúkòkòrò tí Ọba Kútańtì hù yìí, wọn sì kìlọ̀ fún un pé kò gbọdọ̀ pa àgbò Gbọ́lájókòó jẹ, bí ó bá dán an wò, yóò kan ìdin nínú iyọ̀. Kútańtì kò le è pa àgbò ọ̀hún jẹ títí tí àwọn ọdẹ fi dọ́gbọ́n lé e kúrò lórí oyè, tí ó sì rò pé òun sì yẹ̀bá ná ni. Ṣóoróyè tí wọ́n fi ṣe adelé náà gbèrò láti pa àgbò Gbọ́lájókòó jẹ, àmọ́ kò pẹ́ rárá tí àwọn ẹgbẹ́ ọdẹ fi fi ọ̀tẹ̀ lé òun náà kúrò lórí oyè. Lẹ́yìn Ṣóoróyè ni Kúsanrín gba ìjọba, òun kò tilẹ̀ mọ ojú tó fọ́ yàtọ̀ sí àìfọ́ ní tirẹ̀. Bó ṣe ń pa àgbà, ló ń gbẹ̀mí ọmọdé, kí wọ́n lè jẹ́ kí ó rí ìjọba rẹ̀ ṣe. Ó gbé Gbọ́lájókòó àti àwọn ẹmẹ̀wà rẹ̀ jù ṣẹ́wọ̀n, ibẹ̀ ni wọ́n sì kú sí. ìjọba Kúsanrín kò rọrùn rárá, ṣe ni ohun gbogbo le koko bí ojú ẹja. Àṣẹ̀yìnwá, àṣẹ̀yìnbọ̀, ohun tí Kúsanrín kúndùn ni ó gbẹ̀mí rẹ̀, tí ara sì tu mùtúmùwà.

### Ìṣòro Ìbára-ẹni-gbé-pọ̀ Ajẹmóṣèlú nínú Ìwé Orí Mẹ̀kúnnù àti Àgbò-Orí-Ìso

Ohun tí a fẹ́ ṣe níhìn-ín ni ṣíṣe àgbéyẹ̀wò bí àwọn òǹkọ̀wé ṣe ṣàfihàn onírúurú ìṣòro tí ó ń bá àwùjọ fínra ní agbo òṣèlú àtí bí èyí ṣe jẹ́ ìdíwọ́ fún ètò ìbára-ẹni-gbé-pọ̀ tí ó gún régé ní àwùjọ

ẹdá ìtàn. Ó hàn kedere pé àwọn adárí kò nífẹ̀ẹ́ àwùjọ tí wọ́n ń darí. Bí ó ti wù kí ara máa ni ará ìlú tó, fìlà má wobẹ̀ ni àwọn ọ̀jẹ̀lú tí wọ́n pe ara wọn ní òṣèlú wọ̀nyí máa ń dé, èyí tí ó já sí pé ti ara wọn nìkan ni wọ́n mọ̀. Ìwà àjẹ̀ẹ̀wẹ̀yìn kún ọwọ́ wọn pìtìmù, bí àpò tiwọn bá ti ṣuké, àbùṣe-bùṣe. Lára àwọn ìwà kò-tọ́ tí àwọn òǹkọ̀wé àmúlò ṣàfihàn wọn nìwọ̀nyí:

## Ìwà Àjẹbánu àwọn Olóṣèlú àti Níná Owó ní Ìná Àpà

Yorùbá bọ̀, wọ́n ní bí ojú bá ń ṣe ipin, ṣe ni àá yọ ọ́, tí àá fi í han ojú pé ó ń ṣọ̀bùn. Àwọn òǹkọ̀wé àjẹmẹ́fẹ̀ ṣe àmúlò ẹ̀fẹ̀ àti láti tú àṣírí ìwà àjẹbánu àti àjẹ̀ẹ̀wẹ̀yìn tí ó kún ọwọ́ àwọn adarí wa. Ìwà bámúbámú ni mo yó, èmi ò mọ̀ pébi ń pọmọ ẹnikọ́ọ̀kan tí wọ́n ń hù kò jẹ́ kí àlàáfíà jọba ní àwùjọ. Alájẹbánu ni àwùjọ ka àwọn olóṣèlú sí, àpapín ni wọ́n sì ń fi owó ìlú ṣe. ìdàgbàsókè ìlú kò jẹ́ wọ́n lógún, kọ́dà wọn á tún máa kó owó tí ó yẹ kí wọ́n fi tún ìlú ṣe lọ sí òkè-okun láti lọ fí pamọ́. Ìgbádùn ara wọn àti bí ọjọ́ ọ̀la ẹbí wọn yóò ṣe dára ni ó jẹ wọ́n lógún. Nínú Orí Mẹ̀kúnnù, òǹkọ̀wé fi Lísà àti Àró ṣẹ̀fẹ̀ gẹ́gẹ́ bí adarí burúkú. Gbogbo ìlú kó owó jọ fún ìdàgbàsókè ìlú, àwọn olóyè wọ̀nyí sì fi owó náà gbọ́ bùkátà ara wọn. Ìwà àjẹbánu yìí ni ó ṣokùnfà bí wọn ṣe lòdì sí kí Òyékàn jọba, nítorí pé ìyẹn ti sọ pé òun yóò tú àṣírí ìwà ibi tí ẹnikẹ́ni bá hù. Jìnnìjìnnì bo àwọn olóyè wọ̀nyí nígbà tí Òyékàn ń fi èròǹgbà bí yóò ṣe ṣe ìjọba rẹ̀ tó ìgbìmọ̀ afọbajẹ létí pé ìjọba òun kò ní í gba gbẹ̀rẹ́. Olóyè Àró àti Lísà ni òǹkọ̀wé ṣàfihàn wọn gẹ́gẹ́ bí alájẹbánu, tí wọ́n ń ṣe owó ìlú mọ́kumọ̀ku, ìdí nìyí tí wọn kò fi fara mọ́ pé kí Òyékàn di ọba kí àṣírí wọn má bàá tú. Àró àti Lísà fi ara wọn ṣàwàdà wí pé ẹ̀sín wọ́n yóò yọ bí wọn bá jẹ́ kí Òyékàn jẹ ọba.

**Àró**: … ṣe bí o mọ̀ pé nínú owó tí ìlú dá láti fi ṣe omi
ẹ̀rọ àti iná mọ̀nàmọ́ná ni mo yá fi kọ́ ilé mi òkè ọjà.

**Lísà**: Ẹ̀yin gbàgbé ni pé mo jẹ́ ọ̀kan lára alákòóso ilé-iṣẹ́
tí wọ́n gbé kíkọ́ ilé-ìwòsàn tí a fẹ́ kọ́ fún. Ẹ sáà mọ̀
pé láti ìgbà tí a ti ṣe fandẹ́ṣàn tán ni owó ti tán tí
igbó sì ti gba ibẹ̀ lọ́wọ́ wa.

**Àró**: Iná wá fẹ́ẹ́ ràn báyìí. O ò gbọ́ nǹkan tí Òyékàn sọ
ni. Ó ní, "Ìjọba mi kò ní gba gbẹ̀rẹ́ fún ìwà olè,
jìbìtì, wọ̀ǹbílíkí, wọ̀ǹbìà, bámúbámú-ni-mo-yó"
(Fánílọlá 1991: 22)

Bákan náà, ìwà àjẹbánu àwọn agbèfọ́ba nípa owó gọbọi tí wọ́n máa ń gbà lọ́wọ́ àwọn oníṣòwò, lórí ọjà tí ó bá ń wọlé, tí èyí sì máa ń fa ọ̀wọ́n gógó ọjà ni Àró fi ṣẹ̀fẹ̀.

**Àró:** … Eélòó ni yóò wá jẹ́ èrè tèmi nígbà tí èniyàn bá ń
san owó-orí gọbọi lórí àwọn ọjà wọ̀nyí.
Bẹ́ẹ̀ àwọn ọlọ́pàá, adíyelọ́jà àti àwọn òṣìṣẹ́
aṣọ́bodè náà yóò gba ti wọn.
(Fánílọlá 1991: 22)

Nínú Àgbò Orí-Ìso, ìwà àjẹbánu Ṣóoróyè gẹ́gẹ́ bí olè àti olójúkòkòrò ni òǹkọ̀wé fi ṣẹ̀fẹ̀. Ṣóoróyè dorí oyè tán gẹ́gẹ́ bí adelé ọba, ojú rẹ̀ ràn mọ́ ọlá, kò fẹ́ fi ipò sílẹ̀ mọ́. Ó tilẹ̀ rò ó pé ó yẹ kí òun náà di ọba, ṣùgbọ́n ẹ̀rù àwọn ọdẹ bà á. Ó ní:

> … Àbí kí n tiẹ̀ pe àwọn ara ìlú sí ààfin pé kí
> wọ́n jáwé oyè lé mi lórí ni (Ó rẹ́rìn-ín). Háà!
> mo ti gbàgbé pé àwọn ọdẹ ni mo fẹ́ bá tayò.
> Ẹni tó bá dán an wò, bèbè ikú ló ń rìn.
> (Ọdẹ́bùnmi 2009: 84)

Bákan náà, ìwà ọ̀kánjúwà tí ó ṣòódó sára Kútańtì ni Kúsanrín fi ṣẹ̀fẹ̀, olójúkòkòrò àti ò-jẹ-nílé-orò-jẹ-nílé-egúngún ẹ̀dá ènìyàn ni. Kúsanrín fìdí èyí múlẹ̀ nígbà tí ó ń ṣe ìpàdé bòńkẹ́lẹ́ pẹ̀lú àwọn ọmọ-ọdẹ, láti dìtẹ̀ gba ìjọba lọ́wọ́ Ṣóoróyè, tí Kútantì fi ṣe adelé ìjọba rẹ̀. Kúsanrín ní láti kékeré ni Kútańtì ti ya olójúkòkòrò ẹ̀dá, tí ìwà àjẹbánú sì ti di mọ̀líkì sí i lára. Kúsanrín ní:

> Ìbá ṣe pẹ́yin mọ ìtàn, ẹ̀ bá tí dáṣà à ń fi Kútańtì
> jọba. Láti pínníṣín ló ti ń hùwà ọ̀kánjúà…
> (Ọdẹ́bùnmi 2009: 88-89)

Síwájú sí i, nínú Àgbò Orí-Ìso, ọba Kúsanrín kàn ń ná owó ìlú bí ó ṣe wù ú ni. Owó ńlá ńlá ni ó ń gbé ránṣẹ́ sí àwọn tí ó rò pé wọn kò gba ti ìjọba òun, kí wọ́n lè fi ọwọ́ sowọ́pọ̀ pẹ̀lú rẹ̀. Bákan náà ni ó gbé àpò-ìdọ̀họ kọ̀ọ̀kan tí owó tí ó tó ẹgbẹ̀rún lọ́nà igba náírà wà nínú rẹ̀ fún àwọn olù-bá-dámọ̀ràn ibi rẹ̀; ìyẹn Bákàrè, Ọ̀tẹ̀ẹ́dẹ̀rọ̀ àti Oyèéwùnmí. Àádọ́ta mílíọ́nù náírà ni Kúsánrín lọ gbé fún Ọ̀jọ̀gbọ́n Adéyẹmí, kí iyẹn lè pa ẹnu rẹ̀ mọ́ nípa títàbùkù ìjọba rẹ̀, kí òun àti àwọn ẹgbẹ́ afẹ́nifẹ́re lè ṣe ẹnu wọn ní gbọ́lágún, àti pé kí wọ́n lè so ọwọ́ pọ̀ pẹ̀lú rẹ̀. Bákan náà, ẹgbẹ̀rún lọ́nà àádọ́ta náírà ni Kúsanrín fi ránṣẹ́ sí Amòfin Bẹ́ńsìn, ó tún ra àgbò kan ránṣẹ́ sí i pé kí ó fi ṣe ọdún kérésì, kí òun náà lè jẹ́ kí ó fi ẹ̀dọ̀ lérí òrónro ṣe ìjọba rẹ̀. Kọ́lá, ọ̀kan nínú àwọn ẹṣin-ò-kọkú rẹ̀ ni ó fi owó náà rán sí àwọn méjèèjì. Kọ́lá ní:

> Owó ni sà. Àádọ́ta mílíọ́nù náírà péré ni. Kábíyèsí
> ló ní n gbé e fún un yín; wọ́n ní kí ẹ fi ṣèfà jẹ. Wọ́n
> ní kí ẹ jọ̀wọ́, kí ẹ bá àwọn sowọ́ pọ̀ káwọn ó lè ṣe
> ìjọba ìrọ̀rùn. Wọ́n ní báwọn bá pàgbò tó wà lórí ìso,
> àwọn yóò bùn yín jẹ níbẹ̀.
> (Ọdẹ́bùnmi 2009: 100)

Bí a bá wo àwùjọ wa lónìí, a ó ṣàkíyèsí pé ìwà àjẹbánu àwọn tí a yàn sípò ń ṣe ìpalára ńlá fún ìmúgbòòrò àwùjọ. Gbogbo owó tí ó yẹ kí wọ́n lò fún ìdàgbàsókè ìlú ni wọ́n ti fi ṣe àpapín bíi ti Àró àti Lísà. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn Gọ́mínà wa náà ni wọ́n ń kó owó tí ó yẹ kí wọn fi tún ìlù ṣe lọ pamọ́ sí òkè òkun, tí ara sì ń ni àwa níbí. Ìnira tí wọ́n ń kó bá àwọn mẹ̀kúnnù ti pọ̀ jù. Àtijẹun ẹ̀ẹ̀mẹ́ta lójúmọ́ dogun sí ará ìlú lọ́rùn. Kò síṣẹ́, kò sí ohun amáyédẹrùn tí ó dàbí alárà, ọrọ̀-ajé orílẹ̀-èdè dàgẹ̀gẹ́, ètò ààbò mẹ́hẹ, ohun gbogbo dojú rú.

## Níni Mẹ̀kúnnù Lára nípa Gbígba Owó Lọ́nà Àìtọ́

Ní ọ̀pọ̀ ìgbà ni àwọn aṣíwájú wa máa ń gba owó tí kò tọ́ lọ́wọ́ àwọn mẹ̀kúnnù, tí a kò sì ní í mọ ibi tí wọ́n ná owó náà sí. Èyí máa ń wáyé nípa gbígbé òfin tipátipá jáde, tí àwùjọ kò sì ní ní ọ̀nà àbáyọ ju pé kí wọ́n san owó náà. Nínú Orí Mẹ̀kúnnù, gbàrà tí ọba Adékànḿbí ti dórí àlèéfà ni ó ti gbé àwọn òfin kan kalẹ̀, tí èyí sì jẹ́ ìnira àti ìrẹ́jẹ fún àwọn mẹ̀kúnnù. Ó ní ètò ẹ̀dáwó yóò bẹ̀rẹ̀ ní pẹrẹu nítorí àwọn nǹkan tí òun fẹ́ gbé ṣe fún ìdàgbàsókè ìlú. Ó ṣe àlàkalẹ̀ àwọn iṣẹ́ àkànṣe náà; kíkọ́ ààfin tuntun tí ó bá ìgbà mú, kíkọ ilé-ìwòsàn ìgbàlóde, ṣíṣètò omi-ẹ̀rọ àti ìpèsè iná mọ̀nàmọ́ná. Ìdí nìyí tí ọba Adékànḿbí àti àwọn ìjòyè rẹ̀ ṣe sọ owó-orí tí àwọn ọkùnrin ń san

di ìlọ́po méjì oye tí wọ́n ń san tẹ́lẹ̀, tí àwọn obìnrin tí kì í san owó-orí tẹ́lẹ̀ sì bẹ̀rẹ̀ sí ní í san ìlàjí iye tí àwọn ọkùnrin yóò máa san. Náírà mẹ́wàá tí ọkùnrin ń san tẹ́lẹ̀ di ogun náírà, ti àwọn obìnrin sì jẹ́ náírà mẹ́wàá. Kò tán síbẹ̀, ó tún ní ìlù yóò ṣe ìkówójọ fún ìdàgbàsókè ìlú, ọkùnrin yóó san ogọ́jì náírà, obìnrin yóó sì sàn ogún náírà péré. Ọba Adékànmbí ní:

> Nítorí náà, lẹ́hìn ìgbà tí èmi àti àwọn ìjòyè mi ti rò ó síwá, tí a sì rò ó sẹ́hìn, a rí i pé ó pọn dandan láti fi kún owó-orí tí ẹ̀ ń san. Nígbà tí a ti rí i bí òde ṣe rí, ìyẹn bí kò ti ṣe sí owó nígboro, náírà mẹ́wàá ni a fi kún mẹ́wàá tí ẹ̀ ń san tẹ́lẹ̀. (Gbogbo ará ìlú súnra kì, ojú wọn sì korò. Àwọn kan sì ń kùn yunmuyunmu…)
> (Fánílọlá 1991: 48)

Bí a bá wo àwùjọ wa lónìí, a ó rí i dájú pé lóòótọ́ àti òdodo ni ara ń ni ará ìlú, tí ìgbáyé-gbádùn àwọn ará ìlú sì di ìṣòro. Kò tilẹ̀ dàbí ẹni pé àwọn adarí wa ń ro ti àwọn mẹ̀kúnnù mọ́ ètò ìṣàkóso wọn rárá. Etí ọ̀gbọnhin ni igbe mẹ̀kúnnù ń bọ́ sí lára wọn, tí èyí sì mú kí oníkálukú máa wá wọ̀rọ̀kọ̀ fi ṣàdá.

## Àìsí Ìdájọ́ Òdodo

Ní àwùjọ wa, kò sí bó ti tọ́ mọ́, bó ti gbà ló kù. Kò sí ìdájọ́ ododo ní àwùjọ, àṣà kí à gbé ẹ̀bi fún aláre, kí a sì gbé àre fún ẹlẹ́bi ni ó gbòde kan. ọ̀pọ̀ ìgbà ni ó jẹ́ pé àwọn tí à ń wò gẹ́gẹ́ bí ẹni iyì àti ẹni tí ó ṣe é gbẹ́kẹ̀lé, ni ó máa ń gba ìbọ̀dè fún àwùjọ. Púpọ̀ nínú àwọn agbófinró bí i adájọ́, ọlọ́pàá, lọ́yà àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ ni wọ́n jẹ́ alátìlẹ́yìn fún àwọn aṣebi. Àwọn ni wọ́n máa ń yí òfin po, tí wọ́n sì máa ń já àwùjọ kulẹ̀. Nínú Orí Mẹ̀kúnnù, ìwà ìrẹ́jẹ tí ó gbilẹ̀ ní ìlú Tìkàlọ́jù ni Jídé àti Tọ̀mí fi ṣẹ̀fẹ̀. Àwọn jàǹdùkú Adékànḿbí pa méjì nínú àwọn alágbàro Ògúngbè, èyí mú kí Ògúngbè gbé ọ̀rọ̀ lọ sí ilé-ẹjọ́. Lọ́òótọ́, ìjọba ti àwọn jàǹdùkú wọ̀nyí mọ́lé, àmọ́ ṣe ni adájọ dá wọn sílẹ̀ nígbẹ̀yìn gbẹ́yín, tí ó ní àwọn olùpẹ̀jọ́ kò fi ìdí ẹjọ́ wọn múlẹ̀ dáadáa.

**Jídé**: Ah! Ayé yìí ti dorí kodò. Kí a tún máa fi ìyà jẹ ènìyàn lórí nǹkan ẹni lójúkojú báyìí. Ayé wá kọ òótọ́ tán.

**Tọ̀mí**: Èké wá di ohun tó lérè nílùú Tìkàlójù, ká gbẹ́bi fálàre, ká gbáre fẹ́lẹ́bi, àmọ́ ṣá o, kinní kan ló ń gbẹ̀yìn ọ̀rọ̀.

(Fánílọlá 1991:36)

Bí a bá wo àwùjọ wa lónìí, a ó rí i pé ìwà ìrẹ́jẹ yìí náà gbilẹ̀ débi pé ó tẹ́ àwùjọ lọ́rùn láti fara da ìyà tí àwọn alágbára bá fi jẹ wọ́n ju kí wọ́n kó ọ̀rọ̀ wọn lọ sí ilé-ẹjọ lọ, nítorí àìsí ìdájọ́ òdodo, tí èyí sí jẹ́ ìṣòro pàtàkì tí ó ń dí ìdàgbàsókè àwùjọ lọ́wọ́.

## Ìlérí Asán Ṣíṣe

Ọ̀rọ̀ àwọn mẹ̀kúnnù kì í jẹ àwọn adarí wa lógún bí wọ́n bá ti gorí àlèèfà tán. Àsìkò ìbò ni wọ́n máa ń léríléka pé àwọn yóò dogún, àwọn yóò dọgbọ̀n. Ohun tí wọn ò le è ṣe lógún ọdún, ni wọn yóò ṣe ìlérí pé oṣù kan ni àwọn yóò fi ṣe é, bí àwùjọ bá lè fi ìbò gbé wọn wọlé. Bí wọ́n bá ti gorí àlèéfà tán, àbùṣebùṣe, ìfẹ́ inú ara wọn ni ó kù tí wọn yóò máa ṣe. Kì í sí oore kankan lára

wọn bó ti wù ó kéré mọ tí wọ́n ń ṣe fún àwùjọ. Nínú Àgbò Orí-ìsò, Ọ̀jẹ́rìndé ṣàfihàn bí àwọn ọ̀jẹ̀lù tí wọ́n ń pe ara wọn ní òṣèlú ṣe ń fi ìyà jẹ àwọn mẹ̀kúnnù. Ó ní:

> Ṣebí a ráwọn òṣèlú bí wọ́n ti ń ṣe wá. Kí wọ́n tó dórí àlèéfà, gbogbo wọn ni wọ́n léríléka fún wa. Wọ́n dórí àléèfà tán ni wọ́n tàkìtì ìpàkọ́ sí gbogbo mẹ̀kúnnù.
> (Ọdẹ́bùnmi 2009: 69)

Ẹ̀rí tí ó dájú ni pé gbogbo àwọn olóṣèlú ni wọ́n máa ń ṣe ìlérí ohun tí wọn kò le è ṣe ní àsìkò ìbò, ní ète pé kí àwùjọ le è fi ìbò gbé wọn wọlé. Àkíyèsí tí a tilẹ̀ tún ṣe ni pé àwọn olórí wa kì í gbọ́ èdè tí wọ́n fi bá àwọn mẹ̀kúnnù sọ̀rọ̀ mọ́, tí wọ́n bá ti wọlé ìbò, wọn kì í sì mú ìlérí tí wọ́n ṣe ṣẹ.

**Ètò Ààbò tí ó Mẹ́hẹ**

Lára àwọn ìṣòro tí ó ń bá àwùjọ fínra ni àìsí ààbò tí ó péye fún ará ìlú. Ọ̀rọ̀ àìsí ààbò tó péye yìí ti dá ìpayà ńlá sí tolórí tẹlẹ́mù lára. Ilé ò ṣe é dúró sí, òde ò ṣe é lọ. Mélòó ni a fẹ́ kà nínú eyín adípèlé ni ọ̀rọ̀ ètò-àbò tí ó mẹ́hẹ ní àwùjọ. Bí àpẹẹrẹ; ìdigunjalè, ìjínigbé, ìpànìyàn ìgbésùnmọ̀mí, àwọn darandaran náà ò jẹ́ a rímú mí ní àwọn ìgbèríkò; ẹ̀mí ẹran màálú jẹ wọn lógún ju ẹ̀mí ènìyàn lọ, bẹ́ẹ̀ ni àìmoye ẹ̀mí ń ṣòfò lójoojúmọ́ látí ọ̀dọ̀ àwọn Bókò Hàrámù. Ọ̀rọ̀ àìsí ètò ààbò tí ó péye yìí tilẹ̀ ṣe àkóbá ńlá fún ètò ọrọ̀-ajé wa, débi pé àwọn òyìnbọ́ kò le è dá ilé-iṣẹ́ sílẹ̀ mọ́ ní orílẹ̀-èdè yìí. Àwọn ọ̀dọ́ pàápàá ń sá kúrò ní orílẹ̀-èdè yìí, tí wọ́n sí sọ ara wọn di ẹrú ní ìlú onílùú. Àwọn òǹkọ̀wé fi ìdí èyí múlẹ̀ nínú àwọn ìwé àyẹ̀wò nípa ṣíṣe àfihàn bí ètò ààbò ṣe mẹ́hẹ ní àwùjọ ẹ̀dá ìtàn. Nínú Àgbò Orí-ìso, àìmọye ẹ̀mí ni Kúsanrín fi ṣòfò nípa rírán àwọn ẹmẹ̀wà rẹ̀ láti lọ máa pa àwọn tí ó lòdì sí ìjọba rẹ̀. Ó pa Jẹ́jẹ́lọlá, Àlàájì Láwànì àti Àlàájà Sídíkátù. Ó rán àwọn apani-lẹ́kún-jayé sí Àlàájì Gbọ́lájókòó, àmọ́ orí kó ìyẹn yọ. Wọ́n délé Ọ̀jọ̀gbọ́n Adéyẹmí, wọn ò bá a, ìyẹn ti sá lọ sí ilẹ̀ Ìdọ̀mì, ọpẹ́lọpẹ́ àjẹsára ni kò sì jẹ́ kí ó rí Bẹ́ńsìn pa.

**Ọkùnrin kìn-ín-ní**: Jẹ́ẹ́jẹ́lọlá, wòkè kí o wolẹ̀, òní lo ráyé mọ. Wọ́n ti san owó ẹ̀mí rẹ fún wa. A kò ní gba owó tàbí ohun mìíràn lọ́wọ́ rẹ.

**Jẹ́ẹ́jẹ́lọlá**: Háà! Kín ni mo ṣe? Ta ló rán yín sí mi pé kẹ́ ẹ wá pa mí?

**Ọkùnrin Kejì**: Ṣṣṣ…Ṣọ́rọ̀ọ̀pù! Nígbà tó o bá kọjá lọ sálùkìámọ̀, o ó monítọ̀hún.

(Ọdẹ́bùnmi 2009: 106)

Nínú Orí Mẹ̀kúnnù, ọba Adékànmbí pẹ̀lú ìfọwọ́sowọ́pọ̀ Lísà, Àró àti Ọ̀dọ̀fin tí wọ́n jẹ́ olóyè rẹ̀, rán àwọn apànìyàn láti pa Jagun, kí wọ́n sì gbé òkú rẹ̀ sí ẹ̀yìnkùnlé Òyékàn, ní èròǹgbà láti ṣe àkóbá fún Òyékàn. Bákan náà, wọ́n bẹ Kí-ló-fa-mẹ́ẹ̀sì, dírẹ́bà ọkọ̀ àjagbé ejò ọba pé kí ó mọ̀-ọ́n-mọ̀ fi mọ́tò kọ lu Aríjẹ, kí ó sì rí i pé ẹ̀mí bọ́ lẹ́nu rẹ̀ pátápátá. Àwọn ẹni ibi wọ̀nyí pàápàá mọ̀ pé òṣìkà nìwọ́n. Èyí hàn nínú àwàdà tí Lísà àti Àró fi ara wọn ṣe.

**Lísà**: Wò ó, Àró, ìwọ gan-an ni à bá máa pè ní ìjàǹbá-forítì.

**Àró**: Ìwọ náà ńkọ́? Àǹjọ̀ọ̀nú-ìbẹ̀rù

(Fánílọlá 1991: 55)

Bákan náà, Adékànḿbí pa méjì lára àwọn alágbàro Ògúngbè, tí ìyẹn sì pariwo wọ ààfin láti wá fi ẹjọ́ rẹ̀ sun àwọn ìjòyè. Ògúngbè ní:

> Yé! Yé! Yé! Ẹ gbà mi o. Ọmọ ọba Adékànḿbí ti lu méjì pa nínú àwọn alágbàro mi lóko. Ṣe ó ti sọ tẹ̀lẹ̀tẹ̀lẹ̀ pòun kò gbọdọ̀ rí ẹnìkan kan nínú àwọn alágbàro mi àti èmi pààpàá lórí ilẹ̀ náà.

(Fánílọlá 1991: 16.)

### Ìwà Jàǹdùkú, Jàgídíjàgan àti Ìrẹ́nijẹ

Ibi gbogbo ni a ti máa ń kádìyẹ alẹ́ ni ọ̀rọ̀ ìwà ìrẹ́nijẹ, jàgídíjàgan àti jàǹdùkú jẹ́ ní àwùjọ. Àwọn ìwà kò-tọ́ wọ̀nyí máa ń wọ́pọ̀ lágbo ọ̀ṣèlú, pàápàá ní àsìkò ìpolongo ìbò. Nínú Orí Mẹ̀kúnnù, òǹkọ̀wé ṣàfihàn Adékànḿbí gẹ́gẹ́ bí oníjàgídíjàgan, atẹjú-òfin-mọ́lẹ̀ àti aláròékérekè ẹ̀dá. Òun ni ó lọ fún Fádèyí ní ọtí Sàǹfàrì, kí ó lè parọ́ pé òun ni ifá mú láti jọba. Adékànḿbí jẹ́ kí á mọ̀ pé kò sí òfin tí ìjọba ṣe, tí wọn kì í fi àyè rírú sílẹ̀. Bí ìjọba bá sì kọ̀ tí wọn ò ṣe bẹ́ẹ̀, àwọn tí wọ́n ṣe é fún yóò wáyè rírú òfin fún ara wọn. Ó jẹ́ kí ó yé wa pé kò sí òfin tí wọ́n ṣe, tí ó de olówó. Adékànḿbí ní:

> Ẹ̀yin ni ẹ tún ń sọ eléyìí? Bí ẹ ti mọ̀ pé Ọlọ́run kì í ṣe iṣẹ́ rẹ̀ láìfi ààyè ọpẹ́ sílẹ̀. Bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́ náà ni ìjọba ò kì í ṣòfin láìfi ààyè rírú sílẹ̀.

(Fánílọlá 1991: 9)

Ìyálóde náà fẹ̀sùn kan Adékànḿbí pé ó gba ìyàwó àbúrò òun, ó sì túń ń fọ́nnú kiri ìgboro pé olówó ti gbàyàwó ọ̀lẹ (o.i:16). Bákan náà, òǹkọ̀wé ṣàfihàn Adékànḿbí gẹ́gẹ́ bí jàǹdùkú àti arẹ́nijẹ. Ògúngbè ni ó fi idí èyí múlẹ̀, ó ní:

> Òní náà ló pé ọ̀sẹ̀ kan tí ó rán àwọn jàǹdùkú rẹ̀ sí àdúgbò wa láti da ibẹ̀ rú nítorí pé wọ́n kọ̀ láti sà á lọ́ba-lọ̀la, nígbà tí wọ́n gbọ́ dídún fèrè ọkọ̀ rẹ̀…

(Fánílọlá 1991: 16)

Nínú Àgbò Orí-ìso, òǹkọ̀wé jẹ́ kí a mọ̀ pé láti kékeré ni Kútańtì ti ya ìpáǹle. Akinlabí ni àwọn òbí rẹ̀ sọ ọ́. Ìwà ìpáǹle rẹ̀ ni ó jẹ́ kí àwọn ènìyàn máa pè é ní Kútańtì. Àlàní ni ó fi ìdí èyí múlẹ̀ nígbà tí Kútańtì lọ jí àdìyẹ aládìyẹ, tí Àjíkẹ́ ìyàwó rẹ̀ sì fẹ́ẹ́ máa sọ̀rọ̀. Àlàní sọ pé:

> Kò dá mi lójú pé o mọ ìtàn an Kútańtì rárá. Ọgbọ́n àrékérekè rẹ̀ ju ti ọkọ yánníbo lọ. Àkinlabí ni bàbá àti ìyá rẹ̀ sọ ọ́. Ìwà ìpáǹle rẹ̀ ló mú kí àwọn ènìyàn máa pè é ní Kútańtì. Nígbà tí ó ti pé ọmọ ọdún mẹ́jọ ló ti ń dán igbó wò. Ìgbà tí igbó mímu di omi àti ẹ̀jẹ̀ rẹ̀ ni ó dàá lórí rú. Ilé-ìwòsàn Arò ni Abẹ́òkúta ni ó ti di aláwòkù. Ẹni tó réjò rẹ̀ tí kò sá, ara ikú ló ń ré e.

(Ọdẹ́bùnmi 2009: 6)

Àìmọye ènìyàn ni àwọn olóṣèlú àwùjọ wa ti bà láyé jẹ́ nítorí àti dé ipò, nípa ṣíṣe àmúlò àwọn jàǹdùkú, ìpáǹle àti àwọn arẹ́nijẹ, láti ṣe ìpalára fún ẹni tí ó bá ń bá wọn du ipò. Bí wọ́n ṣe ń sọ alátakò di aláàbọ̀ ara, náà ni wọ́n ń ba dúkìá jẹ́ láìbikítà iye tí wọ́n lè jẹ́. Ọ̀nà àtijẹ ti dí mọ́ ẹlòmíràn, tí kò sì rí ọ̀nà àbáyọ mọ́ nípa ìkọlù àwọn jàǹdùkú. Gbogbo àwọn nǹkan wọ̀nyí ni ó ń dí àlàáfíà àwùjọ lọ́wọ́, tí kò sì jẹ́ kí ìdàgbàsókè bá àwùjọ.

## Ìdúnkookò-mọ́ni

Lára ìwà ìbàjẹ́ ni kí ènìyàn máa fi ipò tí ó wà halẹ̀ mọ́ ẹlòmíràn tàbí kí ó máa lo àyè ti ó wà láti fi ọwọ́ ọlá gbáni lójú. Irú èyí tilẹ̀ wọ́pọ̀ lóde òní láwùjọ wa, pàápàá ní agbo òṣèlú. Wọn kì í fẹ́ kí ẹnikẹ́ni bá wọn figagbága, bí a bá sì rí ẹni tí ó bá wọn ṣe oríkunkun, a jẹ́ pé ẹlẹ́kọ ọ̀run ń polówó fún irú ẹni bẹ́ẹ̀ nìyẹn. Nínú Àgbò Orí-ìso, a rí i bi ọba Kúsanrín ṣe dúnkookò mọ́ Gbọ́lájókòó nígbà tí ìyẹn lọ sí ààfin rẹ̀ pẹ̀lú àwọn ará ìlú láti lọ béèrè àgbò rẹ̀. Kúnsanrín jẹ́ kí ó yé Gbọ́lájókòó pé òun á fi imú rẹ̀ dánrin lórí àgbò rẹ̀, tí kò jẹ́ kí òun pa jẹ. Ó ní:

> Ṣé ìwọ ni o kò jẹ́ kí n fẹ̀dọ̀ lérí òróòro láti pàgbò rẹ jẹ?
> Nígbà tí mo bá sọ ọ́ sí ínú ẹ̀wọ̀n tí o pẹ́ níbẹ̀ bí ọ̀bọ, o ó
> panu mọ́ lórí ọ̀rọ̀ àgbò ọ̀hún… Bó o bá fẹ́ràn ara rẹ, jẹ́ kí
> n pàgbò ọ̀hún jẹ kí n lè tú ọ sílẹ̀.
>
> (Ọdẹ́bùnmi 2009: 114)

Tí a bá wo àwùjọ wa lónìí, a ó ṣàkíyèsí pé ọ̀pọ̀ ènìyàn ni ó ti lùgbàdí ọ̀ràn, nítorí pé wọ́n sọ òkodoro ọ̀rọ̀, tí ó ta bá àwọn aláṣẹ, tí èyí sì kó wọn sí wàhálà, tí ó sì dá ẹ̀mí àwọn kan légbodò pẹ̀lú.

## Rìbá Fífúnni àti Gbígbà

Àwọn òǹkọ̀wé àmúlò ṣàfihàn ìwà gbígba rìbá àti àbẹ̀tẹ́lẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ìṣòro tí ó fẹ́ àmọ́jútó ní àwùjọ. Ìwà ìbàjẹ́ yìí gbilẹ̀ tó bẹ́ẹ̀ gẹ́ẹ̀ débi pé gbogbo èèkàn èèkàn ní àwùjọ ni a fẹ́rẹ̀ẹ́ bá imí ẹran nídìí wọn lórí ọ̀rọ̀ rìbá. Nínú Orí Mẹ̀kúnnù, Aríjẹ fi ìdí èyí múlẹ̀ pé bí àwọn àgbèfọ́ba bá ti rí owó, òdodo máa ń ṣòroó sọ fún wọn.

**Aríjẹ**: Owó ló ń sọ̀rọ̀ yẹn.?
**Tọ̀mí**: Ṣe o wá fẹ́ẹ́ sọ pé adájọ́ yẹn gba owó ẹ̀hìn ni?
**Aríjẹ**: Àti owó iwájú pàápàá.
**Tọ̀mí**: Èmi kò rò bẹ́ẹ̀, nítorí adájọ́ náà ní olùpẹ̀jọ́ kò fi ìdí ẹjọ́ rẹ̀ múlẹ̀ dáadáa
**Aríjẹ**: Bí ó bá fi ìdí ẹjọ́ rẹ̀ múlẹ̀ tí adájọ́ ní kò fi múlẹ̀ dáadáa ńkọ́?
**Jídé**: Hẹn, ṣebí á lọ pe ẹjọ́ kò-tẹ-mi-lọ́rùn.
**Aríjẹ**: Òtúbáńtẹ́ náà ni nítorí àpò kan náà ni gbogbo wọn ń pa owó sí.

(Fánílọlá 1991: 39-40)

Rìbá àti àbẹ̀tẹ́lẹ̀ gbígbà náà ló mú kí àwọn afọbajẹ dá ifá nù. Òyékàn ni ifá mú pé yóò jọba, òun sì ni ìrètí àwọn mẹ̀kúnnù. Adékànḿbí gbèyìn lọ fi mọ́tò ayọ́kẹ́lẹ́ kọ̀ọ̀kan ta Àró, Lísà àti Ọ̀dọ̀fin lọ́rẹ̀ pẹ̀lú ẹ̀bùn owó yanturu. Àwùjọ mọ àwọn tí ìwà ìbàjẹ́ lẹ̀ mọ́ lára, wọ́n sì mọ àwọn tí wọ́n wẹ̀, tí wọ́n yán kàn-ìn-kàn. Aríjẹ àti àwọn ọ̀rẹ́ rẹ̀ fi ìdí èyí múlẹ̀.

**Aríjẹ**: …Wọ́n ni Adékànḿbí ti gbé ọkọ̀ ayọ́kẹ́lẹ́ àti ẹgbẹ̀rún mẹ́wàá náírà fún mẹ́ta nínú àwọn afọbajẹ wọ̀nyẹn.
**Jídé**: Àwọn mẹ́ta wo ló lè ṣe ooo?

**Aríjẹ**: Ó dá mi lójú pé olóyè Àró yóò jẹ́ ọ̀kan.
(Fánílọlá 1991: 41)

Ní àwùjọ wa lónìí, ìwà ìbàjẹ́ yìí kò yọ ààrẹ, gọ́mínà, adájọ́, agbẹjọ́rò, ọlọ́pàá, wòlíì, àwọn lọ́gàá lọ́gàá àti àwọn lóókọ lóókọ lẹ́nu iṣẹ́ ọba sílẹ̀. Bí àwọn olóṣèlú bá gbé iṣẹ́ àkànṣe fún kọ̀ǹgílátọ̀, wọ́n á ti gba ìdámẹ́wàá owó iṣẹ́ náà lọ́wọ́ ẹni tí wọ́n gbé e fún, tí owó tí ó kú sì lè má ká iṣẹ́ tí wọ́n gbé fún ẹni náà láti ṣe. Bákan náà ni àwọn olóṣèlú wọ̀nyí máa ń lo rìbá láti pa àwọn abẹnugan ìlú lẹ́nu mọ́, kí wọ́n lè ráyè ṣe tiwọn. Tí wọ́n bá ti fi owó dí wọn lẹ́nu, tí wọ́n sì ti gbé ọkọ̀ bọ̀gìnnìn sí wọn nídìí, òótọ́ ọ̀rọ̀ a ṣòroó sọ, torí pé ẹni tí ó bá ti jẹ dòdò, kò ní í le è sọ òdodo.

## Ìgbani ní Ìmọ̀ràn Ibi

Gbígbani ní ìmọ̀ràn ibi a máá dènà ìlọsíwájú àwùjọ. Àwọn èniyan kan wà ní àwùjọ tí wọ́n gbà pé kò sí ẹni tí ó lè tún àwùjọ tí ó ti bà jẹ́ ṣe. Kàkà kí wọ́n ti ẹni tí ó bá ń gbìyànjú láti tún àwùjọ ṣe lẹ́yìn, ìmọ̀ràn ibi tí kò le è ṣe ìlú ní àǹfààní ni wọn yóò máa fún irú ẹni bẹ́ẹ̀, nítorí àtẹnujẹ. Nínú Orí Mẹ̀kúnnù, Àró, Lísà àti Ọ̀dọ̀fin gba ọba Adékàḿbí ní ìmọ̀ràn láti ṣe àkóbá fún Òyékàn tí wọ́n jọ du oyè ọba, nípa pípa olóyè Jagun, kí wọ́n sì gbé òkú rẹ̀ sí ẹ̀yìnkùnlé Òyékàn. Bákan náà ni wọ́n gba ọba ní ìmọ̀ràn ìkà láti ṣe ikú pa Aríjẹ, tí ó jẹ́ agbónu káká fún àwọn mẹ̀kúnnù.

**Ọba**: … Aríjẹ ńkọ́?
**Àró**: Eléyìí nì kò le.
**Ọba**: Má sọ bẹ́ẹ̀ Àró nítorí àdìrò
wọ́rọ́kọ́ tó tún lè dọbẹ̀ nù lòun náà.
**Àró**: Àní tirẹ̀ yẹn kò jà.
**Ọba**: Ó dáa, ṣàlàyé bí a ó ti yanjú rẹ̀ nítorí
ó ń bọ̀ lọ́kè, àwọn lá ń dẹ́ dè é.
**Àró**: Ṣé ẹ mọ̀ pé kò lè má gun tatapùpù
rẹ̀ lọ sí Ajébámidélé ní ìdìidájí. Bí
a bá ti fún dẹ́rẹ́bà àjàgbé ejò yín ní
owó díẹ̀ kí ó báwa kọ lù ú, kí ó sì
rí i dájú pé ó gbé ẹ̀mí mì lójú ẹsẹ̀,
àbùṣe bùṣe.
**Ọba**: Hún-hùn, ẹ kú làákàyè, ẹ kú ọgbọ́n.
Bí n bá ti rí i yín lọ́tùn, tí mo tún wòsì
mi tí mo rí i yín, ṣe ni ọkàn mi máa ń
balẹ̀ bí ọkàn tòlótòló.
(Fánílọlá 1991: 55)

Nínú Àgbò Orí-ìso, Bákàrè, Oyèwùmí àti Ọ̀tẹ̀ẹ́dẹ̀rọ̀ gba Kúsanrín ní ìmọ̀ràn ibi nítorí àtẹnujẹ. Kábíyèsí béèrè ìmọ̀ràn lórí bí òun yóò ṣe pa àgbò Gbọ́lájókòó jẹ tí kò sì ní séwu fún òun. Ọ̀tẹ̀ẹ́dẹ̀rọ̀ gbà á nímọ̀ràn pé kí ó lọ gbé owó fún àwọn abẹnugan ará ìlú pẹ̀lú ẹ̀bùn tó jọjú. Oyèwùmí ní kí ọba rán apànìyàn sí Gbọ́lájókòó láti pa á, ó ní bí Gbọ́lájókòó bá sì wà láyé kò ní í ṣe é ṣe láti pa àgbò rẹ̀ jẹ. Bákàrè ní tirẹ̀ fara mọ́ àbá méjèèjì pé kí wọ́n fa ojú àwọn abẹnugan wọn mọ́ra kí wọ́n sì yẹjú Gbọ́lájókòó. Inú ọba Kúsanrín dùn sí ìmọ̀ràn ti àwọn ọ̀tá ìlú mẹ́tẹ̀ẹ̀ta wọ̀nyí gbà á, èyí mú kí ó gbé owó ńlá fún wọn. Ìmọ̀ràn tí wọ́n gbà á nìyí:

**Oyèwùmí**: Kábíyèsí, mo fẹ́ kí ẹ mọ̀ pé àtipàgbò Gbọ́lájókòó jẹ ò rọrùn. Gbogbo wọn ni wọ́n ń pariwo ẹnu pé lálà ó lù bí ẹ bá lọ pàgbò Gbọ́lájókòó jẹ. Bá ò bá fógun, tá ò fọ́tẹ̀, ẹ jẹ́ á rán apàyàn sí Gbọ́lájókòó. Bó bá kú tán, ohun gbogbo ni yóó ṣe déédé.

**Bákàrè**: Ìmọ̀ràn méjéèjì lẹ è bá jẹ́ á mú lò. Ká gbówó àtẹ̀bùn fẹni tó tọ́ sí nínú wọn. Bónítọ̀hún bá kọ̀ tí ò gbà, ẹ jẹ́ a kọ lẹ́tà ikú lé e lọ́wọ́. Ẹ jẹ́ á tètè yẹjú Gbọ́lájókòó kí gbogbo ohun tó ń rùn nílẹ̀ ó parí.

**Kúsanrín**: Ẹ̀yin mẹ́tẹ̀ẹ̀ta, ẹ gbé àpò ìdọ̀họ kọ̀ọ̀kan nínú àpò ìdọ̀họ mẹ́tẹ̀ẹ̀ta tó wà nílẹ̀ wọ̀nyẹn. Ẹgbẹ̀rún lọ́nà igba náírà ló wà nínú ọ̀kọ̀ọ̀kan. Ohun tó tọ́ sí yín ni, ẹni ìfà ò tọ́ sí ní í pè é ní hàrámù.

(Ọdẹ́bùnmi 2009: 92-93)

Ní àwùjọ wa, irú àwọn ẹni ibi àti ènìyàn ìkà báyìí ni kì í jẹ́ kí àwùjọ tòrò. A ṣe àkíyèsí pé àwọn kan tílẹ̀ wà tí ó jẹ́ pé ipò olùdámọ̀ràn fún àwọn tí ó wà ní ìgbọ́nnu àṣẹ ni wọ́n dì mú, tí ó sì jẹ́ pé ìmọ̀ràn tí wọ́n bá fún ẹni náà ni ó máa ń tẹ̀lé. Irú àwọn wọ̀nyí ni ó máa ń mú ìnira bá àwọn ará ìlú, tí ohun gbogbo sì máa ń le koko.

## Ìdìtẹ̀ Gba Ìjọba

Lára ìṣòro ajẹmóṣèlú ni a ti rí ìdìtẹ̀ gbàjọba. Jẹ-kí-n-jẹ ni àwọn olóṣèlú máa ń fi ètò ìṣèjọba ṣe, pàápàá ètò ìṣèjọba àwàrawa. Bí wọ́n bá ti rí i pé ẹni tí ó wà lórí oyè kọ́ iyán àwọn kéré, wọn yóò wá bí yóò ṣe kúrò lórí oyè dandan. Nínú Àgbò Ori-ìso, Kútańtì ṣe ìpàdé bòńkẹ́lẹ́ pẹ̀lú àwọn ẹgbẹ́ ọdẹ pé ó yẹ kí àwọn náà gbádùn mùdùn-múdùn ìlú, ó sì ṣètò bí wọn yóò ṣe gbà ìjọba lọ́wọ́ ọba Dánásungbó nípa kíka oríṣiríṣi ẹ̀sùn sí i lẹ́sẹ̀. Kútańtì ní:

> Ẹ̀yin ẹgbẹ́ ọdẹ, ó tó àkókò fún wa kí àwa náà jẹ nínú ìgbàdùn Ibùdó-ọ̀tẹ̀. Gbogbo àwọn ọba tí ó ti ń jẹ nÍbùdó-ọ̀tẹ̀ ni kò náání ìdàgbàsókè ìlú. Wọn kò tilẹ̀ mọ̀ péyà ń jẹ mẹ̀kúnnù. Wọ́n sọ gbogbo ọrọ̀-ajé ìlú di tara wọn… ìwà ọ̀kánjúà ọba Dánásungbò bùáyà. Ẹ̀ bá jẹ́ káwa náà ó jọba ká lè tún Bùdó-ọ̀tẹ̀ ṣe… Ẹ jẹ ń ṣáájú, kí ẹ tẹ̀lé mi, ká lé Dánásungbó àtàwọn olóyè rẹ kúrò láàfin.
>
> (Ọdẹ́bùnmi 2009: 12)

Ògúngbénró tí ó jẹ́ ọ̀kan lára àwọn ọmọ ẹgbẹ́-ọdẹ náà kín àbá Kútańtì lẹ́yìn. Ó ní:

> …Ìkòkò tí ó jata, ìdí rẹ̀ á gbọ́ná. Ẹ máṣe jẹ́ ká fọ̀pá pọ̀ọ̀lọ̀pọ̀ọ̀lọ̀ pejò. Ẹ jẹ́ kí a kẹ́tù-káhàyá, kí a kìbọn ká lọ pọba àtàwọn ìjòyè sáàfin. Ọ̀nà mìíràn kò sí ti a fi lè gàlèéfà.
> (Ọdẹ́bùnmi 2009 : 13)

Ìwà tí Kútańtì hù yìí kò ṣàjèjì sí àwùjọ wa. Àìmọye ìgbà ni àwọn ológun tí dìtẹ̀ gba ìjọba, látàrí ẹ̀sùn pé nǹkan kò fara rọ ní àwùjọ. Àkíyèsí tí a ṣe ni pé irú ìró nìborún ni ọ̀rọ̀ gbogbo àwọn tí ó ń ṣèjọba, àti ológun àti alágbádá, kò sí èyí tí ìjọba rẹ̀ sàn.

### Ìṣòro Àìríṣẹ́ Ṣe

Àìpèsè iṣẹ́ àti ohun amáyédẹrùn fùn àwọn ọ̀dọ́ ni ó mú kí àwọn ọ̀dọ́ ìwòyí máa ń fẹsẹ̀ gbálẹ̀ kiri ìgboro, nígbà tí wọn bá ti sìnrú ìlú tán. Ìdí rè é tí àwọn ọ̀dọ́ láńgbá ṣe máa ń jápa tí ààyè rẹ̀ bá yọ tàbí kí wọ́n dara pọ̀ mọ́ ẹgbẹ́kẹ́gbẹ́, tí èyí sì jẹ́ okùnfà ìwà ìbàjẹ́ tí wọ́n ń hù ní àwùjọ, nítorí ọwọ́ tí ó bá dilẹ̀ ni èṣù máa ń bẹ̀ lọ́wẹ̀. Nínú Orí Mẹ̀kúnnù, Aríjẹ rọ ọba Adékànàbí láti wá nǹkan ṣe sí ìnira tí ó ń dé bá ìlú nípasẹ̀ ọ̀wọ́n gógó ọjà, oúnjẹ, ìwà jàgùdà àti àìsíṣẹ́ lóde fún àwọn mẹ̀kúnnù. Aríjẹ ní:

> …èmi ìbá wá dá a lábàá pé kí ìjọba wá nǹkan ṣe sí ọ̀wọ́n gógó ọjà, oúnjẹ àti pípaná ìwà jàgùdà tí ń jó láàrin ìlú yìí. Páripari rẹ̀, kábíyèsí, kò sí iṣẹ́ lóde. Àwọn ènìyàn kò rí owó ṣíṣẹ́. Nítorí náà, ẹ̀kúnwọ́ owó-orí yìí, àfàìmọ̀ ni kò ní í kó ìnira, wàhálà àti ebi bá ọ̀gọ̀ọ̀rọ̀ àwọn mẹ̀kúnnù ní ìgboro.
> (Fánílọlá 1991: 61)

Aríjẹ tí ó jẹ́ agbẹnusọ fún àwọn mẹ̀kúnnù jẹ́ kí ó yé ọba Adékànḿbí àti àwọn jẹgúdújẹrá ìjòyè rẹ̀ pé wọn gbọ́dọ̀ wá nǹkan ṣe sí gbogbo nǹkan tí ó le koko fún àwọn mẹ̀kúnnù, tí àtijẹun ẹ̀ẹ̀mẹ́ta di ìnira. Àkíyèsí tí a ṣe ni pé ìyà àti ìṣẹ́ tí ó ń bá àwùjọ wa fínra kò ṣẹ̀yín ìwà àjẹbánu àti àìláàánú àwọn olórí wa. Ìwà àìbikítà àti ìwà bámúbámí ni mo yó tí ó gbilẹ̀ sí oọ́kan àyà àwọn olórí wa ṣe àkóbá ńlá fún ìmúgbòòrò àwùjọ. ,

### Ìlò Ẹ̀fẹ̀ fún Yíyanjú Ìṣòro Ìbára-ẹni-gbé-pọ̀ Ajẹmóṣèlú nínú Ìwé Àṣàyàn Orí Mẹ̀kúnnù àti Àgbò Orí-Ìso

Iṣẹ́ yìí ti ṣàfihàn onírúurú ìṣòro tí ó ń jẹ yọ nínú ètò ìṣèlú, ó sì ti ṣàfihàn bí àwọn ìṣòro náà ṣe ń dí àlàáfíà, ìtẹ̀síwájú àti ìdàgbàsókè àwùjọ lọ́wọ́. Oríṣiríṣi ọ̀nà ni àwọn òǹkọ̀wé àmúlò méjèèjì gbà lo ẹ̀fẹ̀ láti wá ìyanjú sí àwọn ìṣòro ìbára-ẹni-gbé-pọ̀ ajẹmóṣèlú. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé kì í ṣe gbogbo ìṣòro tí a tọ́ka sí nínú iṣẹ́ ìwádìí yìí ni àwọn òǹkọ̀wé rí ìyanjú sí, àmọ́ ìwọ̀nba tí wọ́n rí ìyanjú sí lè mú àlàáfíà àti ìtẹ̀síwájú bá àwùjọ tí a bá tẹ̀lé ìlànà ìwòye wọn

### Fífi Ẹ̀fẹ̀ Yanjú Ìṣòro Níni Mẹ̀kúnnù Lára Nípa Gbígba Owó Lọ́nà Àìtọ́ Lọ́wọ́ Wọn

Yorùbá bọ̀, wọ́n ní bí ajá tí ó ti ń rí ènìyàn ju ìrù bá wá ń rí ènìyàn gbó, kí a mọ̀ pé nǹkan ń bẹ, àti pé Yorùbá gbà pé ẹnu ẹni ni a fi ń kọ mé jẹ. Ní ọ̀pọ̀ ìgbà ni àwọn mẹ̀kúnnù máa ń fúnra wọn kọ ìyà tí ó ń jẹ wọn, nígbà tí àwọn adarí bá ti sún wọn kan ògiri. Nínú Orí Mẹ̀kúnnù, àwọn Mẹ̀kúnnù lòdì sí òfin tuntun tí ọba Adékànmbi ṣẹ̀ṣẹ̀ gbé kalẹ̀ nípa pé kí wọ́n tún ṣe ìkówójọ fún ìdàgbàsókè ìlú, lẹ́yìn tí wọn ti ṣe ìkọ́wòjọ kan tẹ̀lẹ̀, tí àwọn kan sì ti kó o ná. Aríjẹ́ tí ó jẹ́ agbẹnusọ àwọn mẹ̀kúnnù lòdì sí àgbékalẹ̀ ọba Adékànmbí yìí. Ìdí ni pé gbogbo owó tí mẹ̀kúnnù

ti ń san látẹ̀yìn wá kò mú ìtẹ̀síwájú bá àwùjọ, bẹ́ẹ̀ ni wọn ò rí kókó ohun tí wọn ń dá owó lé lórí. Ẹ̀fẹ̀ tí Aríjẹ fi àwọn olóyè tí ó wà nídìí ètò ìkówọ́jọ́ tí wọn tí ṣe tẹ́lẹ̀, ni pé 'ìkówọ́jẹ' ni wọ́n ṣe dípò ìkówọ́jọ, nítorí pé wọn kò rí ibi tí owó tí wọ́n kó jọ wọlẹ̀ sí. Ó rọ ọba láti ṣe ìwádìí bí àwọn owó tí mẹ̀kúnnù tí dá sẹ̀yìn ṣe rìn, kí wọ́n tó ṣe ìkówọ́jọ, tí ó pè ní 'ìkówọ́jẹ' mìíràn. Aríjẹ ní:

> … Àmọ́-ọ́ń yinniyinni ní í múni ṣe òmíràn. Tí a ti ń dáwó ìdàgbàsókè ní ìlú yìí, ọjọ́ ti pẹ́, ṣùgbọ́n dípò kí a rí ìdàgbàsókè, ìfàsẹ́hìn ni à ń rí. Dípò Ọláńrewájú, Ọlárẹ̀hìn ni tiwa… Kí ó tó di pé ọba wa àná wàjà ni a ti ń ṣe ìkówójọ fún iṣẹ́ omi ẹ̀rọ, iná mọ̀nàmọ́ná àti ilé-ìwòsàn, kí a má tilẹ̀ sọ ti owó-orí tí a ń san ní ọdọọdún, níbo ni owó ìdàgbàsókè tí wọn kó jọ wọlẹ̀ sí? Ẹ sọ fún wa níbo ni wọ́n bá iṣẹ́ dé lórí omi ẹ̀rọ àti iná mọ̀nàmọ́ná tàbí ilé-ìwòsàn tí a ní a fẹ́ kọ́? Gbogbo àwọn aṣaájú wa ti wọn ń kù fẹ̀rẹ̀ kiri ní àsìkò ìkówójọ náà ni ìrẹ̀wẹ̀sì ti bá pátápátá. Kín ni a wá ń rí báyìí, ìkówójẹ dípò ìkówójọ.
>
> (Fánílọlá 1991: 49-50)

Ẹ̀fẹ̀ tí Aríjẹ fi àwọn ìjòyè tí wọ́n ṣe owó tí ìlú kó jọ mọ́kumọ̀ku ṣe wọ̀ wọ́n lára púpọ̀. A rí Lísà àti Ọ̀dọ́fin tí ara wọn kò lélẹ̀ mọ́ lórí ìjókòó wọn, bí wọ́n ṣe ń kúrú, ni wọ́n ń ga. ìtìjú ẹ̀fẹ̀ yìí mú ọba Adékànḿbí, fún ẹsùn kàǹkà tí wọ́n fi kan àwọn ìjòyè rẹ̀ nípa kíkówó ìlú jẹ. Èyí mú kí ó gbé ìgbìmọ̀ olùwádìí kalẹ̀, tí ó sì pinnu láti gé ìka tí ó bá ṣẹ̀. Ó ní:

> Aríjẹ, ẹ̀sùn tó le pátápátá ni o fi kan àwọn ìjòyè yìí, mo ṣe tán láti gbé ìgbìmọ̀ tí yóò ṣe ìwádìí àwọn ẹ̀sùn wọ̀nyí kalẹ̀ tí a ó sì gé ìka tí ó bá ṣẹ̀.
>
> (Fánílọlá 1991: 50)

Aríjẹ ni ó wá ìyanjú sí ìṣòro ìnilára tí ẹ̀dáwó mìíràn ìbá kó bá àwọn mẹ̀kúnnù, nípa rírọ ọba Adékànḿbí láti dá ìkówójọ tí ó pè ní ìkówójẹ dúró di ìgbà tí àbáyọrí ìgbìmọ̀ yóò jáde, tí èyí sì dùn mọ́ àwọn ìlú nínú nípa ìtura tí ó dé bá wọn. Ó ní:

> …ìbá wá jẹ́ ohun tí ó tọ́ lójú àwọn ará ìlú kí a dá ìkówójọ bọ́yá ìkówójẹ sì ni dúró di ìgbà tí àbáyọrí ìgbìmọ̀ yín yóò jáde…
>
> (Fánílọlá 1991: 50)

Àkíyèsí tí iṣẹ́ yìí ṣe ni pé ọ̀pọ̀ ìgbà ni àwọn olórí wa máa ń fi ọgbọ́n àlùmọ̀kọ́rọ́yí gba owó lọ́wọ́ mẹ̀kúnnù tí èyí sì máa ń jẹ́ ìnilára fún wọn. Àwọn òǹkọ̀wé jẹ́ kí a mọ̀ pé ó ṣe é ṣe fún àwùjọ láti kọ ìyà tí àwọn adarí fi ń jẹ wọ́n, pàápàá, nípa àwọn ẹ̀dáwó kan tí kò ní ìtumọ̀, tí èyí yóò sì fi òpin sí ìwà ìninilára láti ọwọ́ àwọn olórí wọ̀nyí.

## Fífi Ẹ̀fẹ̀ Yanjú Ìṣòro Àṣìlò Ipò

Ìgbàgbọ́ Yorùbá ni pé gbogbo ohun tí ẹ̀dá bá ṣe ni ẹ̀san wà fún. Ìdí nìyí tí wọ́n fi máa ń sọ pé ẹni bá ń ṣe rere, kí ó múra sí i, ẹni tí ó bá sì ń ṣekà náà kí ó tẹra mọ́ ọn, àtoore, àtìkà, ọ̀kan kì í gbé. Akíyèsí tí iṣẹ́ yìí ṣe ni pé ìwà ìkà kún ọwọ́ ọ̀pọ̀ àwọn olórí àwùjọ wa pitimù. Ayé ta ni-ó-mú-mi ni púpọ̀ wọn máa ń jẹ nígbà tí wọ́n bá wà nípò. Ìgbàgbọ́ àwùjọ sì ni pé ẹni tí ènìyàn kò bá le è mú, Ọlọ́run ọba lè mú un, ìdí ni pé gbogbo àwùjọ ni ó ní ìgbàgbó nínú Olọ́dùmarè, ó kàn jẹ́ wí pé

ọ̀nà tí oníkálukú ń gbà sìn Ín ni ó yàtọ̀. Àtubọ̀tán àwọn adarí burúkú kì í dára, ẹ̀sín àti àbùkù tí ìwà ibi tí wọn ti hù máa ń mú bá wọn, máa ń jẹ́ ìtìjú ńlá fún wọn, yálà nígbà tí wọ́n ṣì wà ní orí àlèéfà tàbí nígbà tí wọ́n bá kúrò nípò. Ikú ẹ̀sín ni ọ̀pọ̀ wọn tílẹ̀ máa ń kú.

Nínú Ori Mẹ̀kúnnù, ìgbẹ̀yìn ọba Adékànḿbí burú jọjọ, nítorí ìwà ibi tí ó ti hù, tí ó sì fi ìyà pá àwọn mẹ̀kúnnù lórí lásìkò ìṣèjọba rẹ̀. Wàhálà dé bá ọba Adékàḿbí, kò le è jẹun fún odidi bí ọjọ́ méjì. Kì í ṣe pé ebi kò pa kábíyèsí, oúnjẹ wà níwájú rẹ̀, àmọ́ kò ṣe é ṣe fún un láti jẹ ẹ́, nítorí bí ó bá ti ń mú òkèlè lọ ṣẹ́nu, ni ẹlẹ́dàá Jagun tí ó pa ń di ọwọ́ rẹ̀ mú. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé oúnjẹ ti Adékàḿbí fẹ́ràn jù ni olorì pèsè fún un, àmọ́ ko ṣe é ṣe fún un láti jẹ́ ẹ́.

**Olorì**: Kábíyèsí, ẹ ẹ̀ dẹ̀ rọ́jú kí ẹ jẹ díẹ̀ nínú oúnjẹ yìí. Mo mọ̀ pé iyán lẹ fẹ́ràn jù, òun náà ni mo sì ṣe lọ gún iyán yìí…

**Kábíyèsí**: (Ó ń sọ̀rọ̀ tìrọ́jú tìrọ́jú) Èmi náà kọ̀, ṣe bí mo sọ fún ẹ pé n kò mọ ohun tí ń di ọwọ́ mi mú bí n bá ti ń bu òkèlè lọ sẹ́nu. Ebi ń pa èmi náà.

(Fánílọlá 1991: 68)

Ebi ń pa kábíyèsí, ó ń gbìyànjú àti bu òkèlè lọ sẹ́nu, ṣùgbọ́n bí ó bá ti kù díẹ̀ kí ó mu dé ẹnu ni ọwọ́ rẹ̀ kò níí lè lọ mọ́. Ó tún gbìyànjú àti máa fi ẹnu bu oúnjẹ, ṣùgbọ́n bí ó bá ti kù díẹ̀ kí ẹnu rẹ̀ dé inú abọ́, orí kò ní í lè lọ ìsàlẹ̀ mọ́. Ẹ̀sín tí ó ti ara bí Kábíyèsí ṣe ń fi ẹnu gbé ounjẹ láti inú àwo bí ẹwúrẹ́ yìí kó ìtìjú bá a. Ìtìjú ẹ̀fẹ̀ yìí pááápàá mú olorì pé etí wo ló ń gbọ́ pé odidi ọba ń fi ẹnu gbé ounjẹ nínú àwo, láìṣe ewúrẹ́.

**Olorì**: Ẹ tún ń kírun ni Kábíyèsí?

**Kábíyèsí**: Ṣe ni mo tún ń gbìyànjú láti máa fi ẹnu bu oúnjẹ àbí a á sáà jẹun.

**Olorì**: (ó pàtẹ́wọ́ wàá, wàá, wàá) Eléyìí mà wá dójú ẹ o. Kò bọ́ sí i rárá kábíyèsí. Kí ó wá ṣe ẹnu ni ẹ ó ò máa fi bu oúnjẹ bí ewúrẹ́.

(Fánílọlá 1991: 68)

Ẹ̀fẹ̀ tí Fádèyí, babaláwo fi ọba Adékànḿbí ṣe nígbà tí wọn lọ pè é kí ó wá dífá fún ọba, kí ara rẹ̀ le è yá ni ó kúkú wá fọ́gbá yángan fún kábíyèsí. Ó fi ìwà ìkà kábíyèsí wé oró ríran, tí ó sì gbàgbé pé orí jà joògùn lọ. Ó ní:

> Kábíyèsí, ẹ ti ránró fáwọn mẹ̀kúnnù. Orí àwọn mẹ̀kúnnù
> ló sì wà nídìí ọ̀rọ̀ yìí… Ọ̀kú ọ̀run tún wà lára wọn.
>
> (Fánílọlá 1991: 74)

Ìṣẹ̀lẹ̀ yìí ni ó wá ìyanjú sí ìṣòro tí ó ń bá ara ìlú fínra nípasẹ̀ ìṣèjọba lọ́nà àìtọ́ àti ìyà tí ọba Adékànḿbí fi ń jẹ ará ìlú. Àtúbọ̀tán ìwà ibi ọba Adékànḿbí ni pé ó kú; àlàáfíà jọba ní àwùjọ, ara sì tu àwọn mẹ̀kúnnù.

## Fífi Ẹ̀fẹ̀ Yanjú Ìṣòro Ìjẹgàba àwọn Alágbára

Ní ọ̀pọ̀ ìgbà ni ó jẹ́ pé àwọn olórí wa kì í ṣe ẹ̀tọ́ fún àwọn mẹ̀kúnnù bí wọn kò bá jà fún ẹ̀tọ́ wọn. Ní àwùjọ Nàìjíríà, èdè kan ṣoṣo ti àwọn olórí wa gbọ́ ni kí àwọn òṣìṣẹ́ da iṣẹ́ sílẹ̀, nípa yíyan iṣẹ́ lódì tàbí kí wọ́n ṣe ìwọ́de. Èyí sì máa ń wá ìyanjú sí ìṣòro tí wọ́n bá titorí rẹ̀ jà, kíákíá ni wọn máa ń ṣe ohun tí ìlú ń bèèrè, tàbí kí wọ́n pẹ̀tù sí wọn lójú. Ohun tí wọ́n ń béèrè lè jẹ́ nípa

ẹdínwó lórí ọ̀wọ́n gógó epo pẹtiró tàbí bíbéèrè fún ẹ̀kúnwó owó-oṣù, ó sì lè jẹ́ nípa fífi èhónú hàn lórí ètò ààbò tí ó mẹ́hẹ tàbí ètò ọrọ̀-ajé tí ó dà gẹ̀gẹ́.

Nínú Orí Mẹ̀kúnnù, àwọn mẹ̀kúnnù fi ẹ̀hónú wọn hàn lórí bí ọba Adékànḿbí ṣe ń ṣe ìjọba fàmílétè-n-tutọ́, tí ara sì ń ni ará ìlú. Kò sìṣẹ́, ètò ààbò mẹ́hẹ, ohun gbogbo ló wọ́n gogo. Pabanbarì rẹ̀ ni pé ọba Adékànḿbí tún ń ni àrá ìlú lára nípa sísan owó-orí gegere àti owó ìdàgbàsókè ìlú, tí ó sì jẹ́ pé àwọn kan ni ó ń kó owó náà jẹ. Ẹ̀yí mú kí gbogbo ìlú kóra jọ, tí wọ́n sì forí lé ààfin, wọ́n ń kọ orin àbùkù àti ẹ̀sìn láti fi ọba Adékànḿbí ṣẹ̀fẹ̀ pé ìjọba rẹ̀ kò tẹ́ wọn lọ́rùn, ní èròǹgbà láti lé e kúrò lórí oyè.

**Orin**: Kóró kóró lojú ìlú le
**Ègbè**: Yàyà Olóro
**Ẹnìkan**: Ó tóóóó! (ọ́ dá orin)
**Lílé**: Mẹ̀kúnnù ò ní gbà
**Ègbè**: Ó ró ya-ya-ya, ó ró
**Lílé**: Tálíkà ò ní gbà
**Ègbè**: Ó ró ya-ya-ya, ó ró (wọ́n wọlé pẹ̀lú kùmọ̀ àdá àti ààké lọ́wọ́. Wọ́n tún dá orin mìíràn)
**Orin**: Ohun tí ó gbà la ó fun. Ẹnìkan ì ṣe wèrè. Ẹ̣ má fọ̀bọ lọ̀ wá. Ohun tí ó gbà lá ó fun

(Fánílọlá 1991: 83-84)

Ìtìjú ẹ̀fẹ̀ tí àwọn mẹ̀kúnnù fi ọba Adékànḿbí àti àwọn ìjòyè rẹ̀ ṣe, nípa kíkò wọ́n lójú, tí wọ́n sì sọ fún wọn pé wọ́n ń dóoru mú mẹ̀kúnnù wọ̀ wọ́n lára. Ìyálóde ni ó fi oǹdè oògùn na Adékànḿbí, tí ó ṣubú lulẹ̀, tí ó sì ń da itọ́ lẹ́nu, kí ó tó kú. Bákan náà, àwọn ará ìlú de Ọ̀dọ̀fin àti Àró lọ́wọ́ sẹ́yìn, wọ́n sì de ọwọ́ Olorì sí iwájú. Wọ́n bẹ̀rẹ̀ sí ní í nà wọ́n, wọ́n sì ń fi ọwọ́ lẹ̀ wọ́n ní imú. (o.i. 83-84). Ìjàjàgbara àwọn mẹ̀kúnnù yìí ni ó yanjú ìṣòro ìjẹgàba àwọn ajunilọ, tí àlàáfíà sì jọba ní ìgbẹ̀yìn.

Nínú Àgbò Orí-iso, àwọn Mẹ̀kúnnù fi Kútańtì ṣẹ̀fẹ̀ nítorí ìwà ọ̀kánjúwà tí ó hù nípa gbígbẹ́ṣẹ̀lé àgbò tí àwọn ará ìlú rà fún Gbọ́lájókòó láti fi ẹ̀mí ìmoore hàn sí i fún ìwà rere tí ó ń hù ní àwùjọ. Kò sí orúkọ tí wọn kò ṣàìpè é tán; wọ́n pè é ní olè àti ọ̀kánjúà, wọ́n pè é ní olóríburúkú pẹ̀lú. Bí wọ́n ṣe ń ru pósí, ni wọ́n ń tu adìẹ-ìrànà. Àdá ń kọ mọ̀nà lọ́wọ́ àwọn èniyàn kan, bẹ́ẹ̀ ni ìbọn ń dún lákọlákọ. Ìdí ti wọ́n fi ń ṣe ìwọ́de yìí ni láti sọ fún ọba Kútańtí pé ọ̀rọ̀ rẹ̀ ti sú àwọn, kí ó kúrò lórí oyè. Wọ́n ní:

**Lílé**: Gídígbò gídígbò (ẹẹ̀mejì)
**Ègbè**: Héè (ẹ̀ẹ̀mejì)
**Lílé**: Kútańtì
**Ègbè**: O o lè è
**Lílé**: Ọ̀kánjúà
**Ègbè**: O o lè è
**Lílé**: Owó olówó
**Ègbè**: O o lè è
**Lílé**: Ẹran ẹlẹ́ran
**Ègbè**: O o lè è
**Lílé**: Kútańtì
**Ègbè**: O o lè è

| | |
|---|---|
| **Lílé**: | Kò le è jáde (ẹ̀ẹ́mejì)<br>Olóríburúkú tilẹ̀kùn mọ́rí |
| **Ègbè**: | Kò le è jáde |
| **Lílé**: | Kútańtì tilẹ̀kùn mọ́rí |
| **Ègbè**: | Kò le è jáde |
| **Lílé**: | Ọ̀kánjúà tilẹ̀kùn mọ́rí |
| **Ègbè**: | Kò le è jáde |

(Ọdẹ́bùnmi 2009 : 76-77)

Ẹ̀fẹ̀ tí àwọn mẹ̀kúnnù fi Kútańtì ṣe dùn ún wọ inú eegun. Ìtìjú ẹ̀fẹ̀ yìí kò jẹ́ kó jáde sí àwọn tí ó kọrin ẹ̀fẹ̀ bú u, àmọ́ o rí ipa ẹ̀fẹ̀ tí wọ́n fi ṣe náà ní ara rẹ̀, tí ó fi fi ẹnu ara rẹ̀ sọ fún àwọn ìjòyè rẹ̀ pé ọ̀rọ̀ àwọn ará ìlú ti sú òun. Ó ní:

> Ẹ̀yin ìjòyè ìlú, ọ̀rọ̀ ìlú Ibùdó-ọ̀tẹ̀ ti sú mi. Láti ọjọ́ tí wọ́n ti ṣe ìwọ́de ni n ò ti róorun sùn mọ́. Àlákálàá ni mò ń là. Bí ó bá ṣe pé mo dúró lásán ni, àkùkọ-ọ̀run ìbá ti rọ́jà tà. Èwo lẹ fẹ́ kí n ṣe gbogbo ẹ̀yin ìjòyè?
>
> (Ọdẹ́bùnmi 2009: 80)

Ẹ̀fẹ̀ tí àwọn ará ìlú fi Kútańtì ṣe dẹ́rù bà á, ó sì kó ìtìjú bá a. Èyí mú kí ó sá kúrò ní ìlú, tí ó sì fi orí oyè sílẹ̀. Ó ní:

> …Mo fẹ́ fi ìgbà díẹ̀ kúrò láàfin lọ sí ìlú tó jìnnà. Bí mo bá ti kúrò ní ìlú, kí o yáa máa jayé ọba lọ. Bá mi mójú tó àgbò tí mo so mọ́lẹ̀ kí n tó ti ìrìn-àjò dé. Bí mo bá dé ká jọ fi ṣata.
>
> (Ọdẹ́bùnmi 2009: 80)

Gẹ́gẹ́ bí a ti sọ ṣáájú, ìfinìṣẹ̀fẹ̀ lè mú kí oníwà ìbàjẹ́ sá kúrò ní ìlú, bí oró ẹ̀fẹ̀ bá wọ̀ ọ́ lára dáadáa. Gẹ́gẹ́ bí a ti rí i nínú àpẹẹrẹ òkè yìí, Kútańtì sá kúrò lórí oyè nígbà tí ìlú fún ogun mọ́ ọn. Èyí sì jẹ́ àríkọ́gbọ́n fún àwọn mìíràn.

## Àgbálọgbábọ̀

Iṣẹ́ ìwádìí yìí ṣe àkíyèsí pé ètò ìṣèjọba àti ìdájọ́ ìgbàlódé tí a jogún láti ọ́dọ̀ àwọn Òyìnbó amúnisìn ṣe àkóbá ńlá fún àṣà àti ìṣe àwùjọ wa. Èyí ni ó fà á tí ẹ̀fẹ̀ kò fi rí ẹsẹ̀ walẹ̀ mọ́ nínú ìmúdúró ṣinṣin àwùjọ. Láyé àtijọ́, bí ènìyàn bá ń hu ìwà rere, bí kò tilẹ̀ lówó lọ́wọ́, àwùjọ á foyè dá irú ẹni bẹ́ẹ̀ lọ́lá. Bí eniyàn bá sì hu ìwà àbùkù, kò ná àwùjọ ní ohunkóhun láti fi irú ẹni bẹ́ẹ̀ ṣe ẹ̀fẹ̀, kí ó lè jẹ́ àríkọ́gbọ̀n fún àwọn mìíràn. Àpẹẹrẹ èyí ni ti ọba Jáyin ní ìlú Ọ̀yọ́, tí ó pa ọmọ rẹ̀ nítorí owú jíjẹ. Bí ó ṣe kù dẹ̀dẹ̀ kí àwọn eléégún gbé iwì ká a mọ́ ààfin, ni ó rẹni ta á lólobó, ni ọba bá ṣe bí ọkùnrin, nítorí ó mọ̀ pé ikú yá ju ẹ̀sín lọ. Àmọ̀ ní ayé òde-òní, àwọn oníwà ìbàjẹ́ gan-an ni àwùjọ ń pọ́nlé jù, àwọn tí ó yẹ kí wọ́n fi ṣe ẹlẹ́yà ni wọ́n máa ń ṣe àyẹ́sí ńlá fún. Àkíyèsí tí iṣẹ́ ìwádìí yìí ṣe ni pé òfin aṣẹ̀málù tàbí ìmúnitì tí àwọn adarí ìjọba ń jẹ ìgbàdùn rẹ̀ mú kí ìwà ìbàjẹ́ máá gbilẹ̀ sí i, èyí kò sì fi àyè gba ẹ̀fẹ̀ láti fẹ̀.

Yàtọ̀ sí èyí, iṣẹ́ ìwádìí yìí ṣe àkíyèsí pé ẹnikẹ́ni tí ó bá ṣe àyà gbàngbà láti kojú àwọn aláṣẹ, nípa sísọ fún wọn pé ohun tí wọ́n ń ṣe kù díẹ̀ ká-à-tó, lè kan ìdin nínú iyọ̀, tí èyí sì lè mú kí

ó gba ọjọ́ ikú rẹ̀ tàbí kí ó lùgbàdí ẹ̀wọ̀n. Òfin tuntun tí ìjọbá gbé kalẹ̀ lórí pé àwùjọ kò le è sọ òkodoro ọ̀rọ̀ bí ó ṣe wù wọ́n sí àwọn aláṣẹ, ká àwọn aṣẹ̀fẹ̀ àti àwọn òǹkọ̀wé lọ́wọ́ kò, láti ṣe ìgbéláruge ìwà ìkóra-ẹni ní ìjánu. Lọ́òótọ́, ìlò ẹ̀fẹ̀ fún ìyanjú ìṣòro àwùjọ fẹsẹ̀ múlẹ̀ nínú àwọn ìwé àpilẹ̀kọ alátinúdá gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hàn nínú àwọn ìwé àṣàyàn, àmọ́ bí a bá wo inú àwọn ìwé tí ó ti fẹsẹ̀ múlẹ̀ náà, wọn kì í lè mọ́jú-ajé-ko-onísọ̀. Àyípadà máa ń dé bá ibùdọ́ ìtàn àti orúkọ àwọn olùfaragbà. Èyí ń rí bẹ́ẹ̀ kí wọ́n má bà á lu ìgbàdí ẹ̀sùn ìbanilórúkọjẹ́, tí olùfaragbà-ẹ̀fẹ̀ lè fi kàn wọ́n (defamation of character), èyí sì ní ìjìyà tí ó lóòrìn lábẹ́ òfin. Bákan náà, iṣẹ́ ìwádìí yìí ṣe àfihàn pé kò sí ẹni tí kò le é ní ìṣòro, àmọ́ ìpamọ́ra, ìforítì àti sùúrù le è mú kí ènìyàn borí ìṣòro yòọ́wù kí ó jẹ́.

Síwájú síi, iṣẹ́ ìwádìí yìí gbà pé ìlò ẹ̀fẹ̀ ń ṣe àtúnṣe sí àwọn ìwà kò-tọ́ ní àwùjọ, gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hàn nínú àwọn ìwé àyẹ̀wò, tí a sì rí àpẹẹrẹ rẹ̀ nínú ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó ń ṣẹlẹ̀ ní àwùjọ. Bí a bá wo àsìkò ìṣèjọba ọ̀gágun Ibrahim Bàbáńgídá tí ó fi ayé ni àwùjọ lárá, tí kò fẹ́ẹ́ fi ayè gba òṣèlú tiwa-n-tiwa, a ó rí i pé ẹ̀fẹ̀ tí àwọn ará ìlú fi ṣe jẹ́ ọ̀kan pàtàkì lára ohun tí ó lé e kúrò lórí àlèéfà. Tipátipá ni ó fi fi ipò náà sílẹ̀, tí ó ní òun yẹ̀bá fún sáà kan ná. Èyí wáyé látàrí bí àwọn ará ìlú ṣe ń fi ṣẹ̀fẹ̀, tí wọn ń fínná mọ́ ọn, tí ara ò rọ okùn, tí ara ò sì rọ adìyẹ rẹ̀. Èyí ń fi hàn pé ẹ̀fẹ̀ jẹ́ iṣẹ́ tí ó yẹ kí ó jẹ́, nítorí pé àtúbọ̀tán rẹ̀ jẹ́ àríkọ́gbọ́n fún ẹlòmíràn, tí èyí sì jẹ́ ẹ̀kọ́ ìwà ìkóra-ẹni-ní-ìjánu ńlá fún àwùjọ, pàápàá àwọn olóṣèlú.

Lákòòtán, iṣẹ́ ìwádìí yìí jẹ́ kí ó di mímọ̀ pé “Mo rí ọ” ni ẹ̀fẹ̀ jẹ́, bí àwọn ènìyàn bá ń ṣe nǹkan ìkọ̀kọ̀, tí wọ́n rò pé aráyé kò rí àwọn, aṣẹ̀fẹ̀ yóò sọ pé, “A rí i yín o”.

## Àbá fún Ọjọ́ Iwájú

Iṣẹ́ ìwádìí yìí dábàá pé kí ìjọba dín agbára òfin aṣẹ̀málù tàbí ìmúnitì kù, kí àwọn olórí tí wọ́n ń ṣe àkóso lè mọ̀ pé bí wọ́n bá kọjá àyè wọn, nípa híhùwà kò-tọ́ nínú ètò ìṣèjọba, wọ́n lè kan ìdin nínú iyọ̀. Bákan náà, kí ìjọba dẹ́kun sísunni ní ẹ̀sùn ìbani-lọ́rúkọ-jẹ́ sí kóòtù, pàápàá tí ó bá jẹ mọ́ ẹ̀fẹ̀ tí ó dá lórí òdodo. Iṣẹ́ ìwádìí yìí dá a lábàá wí pé kí àwọn òǹkọ̀wé alátinúdá má káàrẹ̀ nípa kíkọ àwọn ìwé ajẹmẹ́fẹ̀ àti ajẹmáwàdà, yálà ìtàn-àròsọ, eré-onítàn tàbí ewì, láti máa fi tú àṣírí àwọn amóòkùn-ṣìkà àti àwọn oníwà ìbájẹ́ tí wọ́n rò pé àwùjọ kò rí wọn, nípa ṣíṣe bẹ́ẹ̀, ẹ̀kọ́ ìwà ìkóra-ẹni-ní-ìjánu àti ìwà ọmọlúàbí yóò lè fẹsẹ̀ múlẹ̀ dáadáa, níwọ̀n ìgbà tí ó jẹ́ pé àwòjíìji àwùjọ ni iṣẹ́ ọnà alátinúdá jẹ́.

Ní àfikún, iṣẹ́ ìwádìí yìí dábàá pé kí ìjọba àti àwùjọ yéé máa fi ọwọ́ rọ́ gbogbo àṣà àtijọ́ tí ó ń mú ìtẹ̀síwájú bá àwùjọ sẹ́yìn, kí a máá ṣe àmúlò èyí tí ó wúlò níbẹ̀, kí a má jẹ́ kí àṣà ìgbàlódé jẹ gàba lórí àṣà ilẹ̀ wa, nítorí pé ọmọ àlè ní í fi ọwọ́ òsì júwe ilé bàbá rẹ̀. Kí a gbìyànjú láti máa lo ọgbọ́n ìjìnlẹ̀ tí àwọn baba wa lò ní ìgbà ìwásẹ̀, nípasẹ̀ ẹ̀kọ́ ìwà àjèjí-ọwọ́-kan-kò-gbẹ́rù-dóri, tí ayé fi rójú ráyè, tí ìlú sì tùbà-tùṣẹ ní ìgbà tiwọn.

Lákòòtán, iṣẹ́ yìí dábàá pé kí ìjọba máa díjú sí ẹ̀fẹ̀ tí àwùjọ bá ń fi àwọn oníwà ìbàjẹ́ ṣe, pàápàá àwọn olóṣèlù, kí wọ́n lè yí ìwà padà, fún ìmúdúró àti ìdàgbàsókè àwùjọ. Kí àwọn aṣíwájú fi àyè gba ìlò ẹ̀fẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ohun èlò ijánu fún ìwà ìbàjẹ́, nípa dídẹ ọwọ́ òfin tí ó ká àwọn òǹkọ̀wé, akéwì, ọ̀kọrin àti oníròyìn lọ́wọ́ kò láti sọ ojú abẹ níkòó, kí ẹ̀mí ìkóra-ẹni-níjàánu lè fẹsẹ̀ múlẹ̀ sí i ní àwùjọ.

## Ìwé Ìtọ́kasí


A Dictionary of the Yorùbá Language (2008). Ìbàdàn: UPL.

Adéfowópè, G.O. (2014). Àfiwéra Kókó-ìtàn, ìfiwàwẹ̀dá àti ìlò-èdè nínú ìwé eré-oníṣe èyí tí akọ kọ àti èyí ti abo kọ. M.A Thesis: Department of Nigeria and Foreign Languages; Faculty of Arts, Ọlábísí Ọnábánjọ University, Àgọ́-ìwòyè.

Adégbìtẹ̀, T. (2019)., Nigeria's Comedy Industry–Joking into Billions' https://www.linkedin.1omlpul . Retrived in October, 2021.

Adéjùmọ̀, A. (2001)., "Ìṣẹ̀fẹ̀ nínú àwọn eré-onítàn Yorùbá". Ph.D Thesis, Cape Town: Centre for Advance Studies of African Society.

Adéjùmọ̀, A. (2007). "Satire as a form of Social control: Its Manifestations in Yoruba Ritual and Festival Songs" *ORITA*, xxxix, 1, pp 27-40.

Adéjùmọ̀, A. (2008). "Satirical Element in the Drama of Akinwumi Iṣọla". Akínyẹmí, A and Fálọlá, T. (eds) *Emerging perspectives on Akinwumi Iṣola Treanton*: Africa World Press, pp 49-62.

Adékúnlé, I.J. (2014). "Satire performatiity of stand-up comedy in Nigeria". A Dissertation submitted to the department of English, Faíulty of Arts, Uniersity of Ibadan, Ibadan in partial fulfillment of Requiremants for the award of Master of Phiolosophy in English.

Adélékè, D.A. (2006). "Ìfagagbága àwọn Aláṣẹ àti Mẹ̀kúnnù nínú Fíìmù ìjà Òmìnira àti Ṣaworo-Idẹ". *Láàńgbásà: Jọ́nà Iṣẹ́ Akadá ní Èdè Yorùbá*. (11), pp 171-176.

Adéòtí, G.R. (1994). "Nigerian Literary Drama and Satire Mode as Exemplified in Wole Soyinka's Works". Unpublished M.A. Thesis, Obafemi Awolowo University, Ile-Ifẹ.

Adéòtí, G.R. (2000) "Satire in Modern Nigerian Threatre: A Historial Exploration", *Isal: Ife Studies in African literature and the Arts*: 1(2), pp 160-171.

Adéọ̀ṣun, O. (2017). "Èrò Báyéṣerí Ọ̀jọ̀gbọ́n Àlàbá Lórí ọ̀rọ̀ Ẹ̀sìn nínú Àṣàyàn Àròfọ̀". A Festschrift for Olúgbóyèga Àlàbá. Department of Linguistics, African and Asian Studies, Faculty of Arts, University of Lagos, Nigeria. pp 517-519.

Ajíbádé, G.O. (2003). "Àgbéyẹ̀wò Awo Ọ̀ṣun àti Àwùjọ́ Òṣogbo nínú Iṣẹ́ Ọnà Ajẹméwì àti Ajẹmáwòrán". Ph.D Thesis, Department of African Languages and Literature, Ọbáfẹ́mi Awọ́lọ́wọ̀ University, Ilé-Ifẹ̀.

Aransi, A.O. (2010). "Àgbékalẹ̀ Ojú Àmúwayé Yorùbá ni ìlànà Eré-Oníṣe nínú ọdún ìgogo ní ìlú Ọ̀wọ̀". A Ph.D Thesis, Department of African Studies, Obáfẹ́mi Awọ́lọ́wọ̀ University, Ilé-Ifẹ̀.

Fánílọlá, K. (1991). *Orí Mẹ̀kúnnù*. Ìbàdàn: Tafak Publications.

Fáṣehùn, M.A. (2017). "Ìlò Àmì nínú Ọdún Ògún ní ìlú Òǹdọ́". Current Studies in Yorùbá Culture, Language and Literature. A Festschrift for Olugboyega Alaba. Department of

Linguistics, African and Asian Studies, Faculty of Arts, University of Lagos, Nigeria. p 161.

Ọdẹ́bùnmi, O. (2009). *Àgbò Orí-Ìso*. Ìbàdàn: Wider World Press.

Ọ̀pẹ́fèyìtímì, A. (2014). *Tíọ́rì àti Ìṣọ́wọ́lò Èdè*. Ilé-Ifẹ̀: Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ University Press.

Raj Kishor, S. (2012). "Humour, Irony and Satire in Literature". International Journal of English and Literature (IJEL). Vol. 3, (4). p. 66-72 TJPRCPVL. Ltd. Sanothimi Campus, Triban University, Kathmandu, Nepal. Retrived Sept. 2022 From<http://en. Wikipedia.org/wiki/humour.

Wahab, I. A. (2022). "Exploring the Theme of Politics and Human Relations in Selected Túndé Kèlání Films". A Ph.D. Thesis, Department of Linguistics and Nigerian Languages, Ọlábísí Ọnàbánjọ University, Àgọ́-Ìwòyè.